Ìgbàsókè Naa

Yuma, Arizona, USA
Ojo Kerin, Osu Kejila, 1965

1 … ni Yuma. Anfaani nla lo ję lati ni ìpè yii lati tun pada wa. A ni àkókò to dara nigbati a wá sibi kéyìn, nigbati mo si gbọ wipe n o tun pada wa, o mu inu mi dun gan-an ni. Lati gbọ awọn ijęri ati awọn ọrọ to dara yii lati ọdọ awọn eniyan, o maa n sọ eniyan ji dię sii.

2 Billy sọ fun mi wipe arakunrin naa lati Las Vegas ti o n fę ipade kan ni ęka ti o wa nibę, n ó rii ni kété ti ipade ba ti pari nihin. O sọ wipe a ni àkókò ti a le ki bọ inu ara wọn ni osu kinni, ki awọn ipade ni Phoenix to bęrę (se ę rii?) lati wa si Las Vegas. A si ti n fę lati de ibę tęlę. Mo gbagbọ wipe arakunrin Art Wilson ti maa n wa nibę lọjọ pipę sęyin, tabi ki o tilę si wa nibę. O sọ fun mi wipe ki n wa, oun ati Arabinrin Wilson. N ko ni anfaani, nitorinaa, boya asiko yii ni n o lee wa.

Se e ri Billy Paul tabi Arakunrin Roy Borders - mo lero wipe o wa nibikan nibi yii. Ẹnikan sọ wipe Arakunrin Roy wa ni … Arakunrin Pearry, Lee, tabi ẹnikęni ninu wọn, wọn yoo lee sọ fun ọ, wọn o si sọ awọn ọjọ ti a o wa.

3 Bayi, mo ri ọpọlọpọ awọn oniwaasu nibi laipę yii, inu mi si dun lati ba awọn arakunrin mi pade. O wu mi ki n ni akoko … ki n ba yin lọ si ile, nitori mo mọ wipe ę ni alásè ti o dara julọ ni gbogbo orilę-ede yii. Iyęn dara.

Arakunrin Pearry ni nkan meji lọrun rę lalę oni. Awọn nkan meji lo tako o bayi; ọkan ninu wọn ni wipe o ge gbohungbohun ti o wa ni nibęyęn. O jębi iyęn, Arakunrin Pearry. N ko ro wipe o jębi gan-an, sugbọn o…. "Ẹnikan n fę lati sọrọ." Iyęn dara.

Pęlupęlu, o tun jade lọ si ibęyęn o si n sọrọ; o na, "Sọ…." O n sọ fun Arakunrin Colins tabi awọn kan ninu wọn, o ni, "Ounję alę yęn dara, sugbọn," o ni, "mo n sọ fun yin," o ni, "ọkunrin yęn nilati ję ara Spain, tabi nkankan bęę, tabi ara Mexico. Ata ti o ta ju ti mo ti i ję ri niyęn!" o n tęsiwaju bęyęn, o si n ba olori alásè naa sọrọ.

O ni, "Emi ni olori alásè naa."

Bi Texas se ri niyęn. A o tọọ sọna ni Arizona nihin ti o ba se dię si i, ti o ba pę nihin, tabi bęękọ?

O dara gan-an lati wa nibi. Mo si lero wipe iyęn ko dà bi i ẹ̀fẹ̀ asan, sugbọn bikose awada. Ti o si ję wipe Oluwa funra Rę ni ònmọ̀ awada, se ę mọ. O ni … Herọdu, "Ẹ lọ sọ fun kọlọkọlọ yęn … [Se e rii?]. Mo n lé ęmi esu jade loni, ati lọla, a o sọ Mi di pipe." Nitorinaa, ti O ba ni ònmọ̀ awada, eese, n ko ro wipe o le pa awa naa lara, lęękọọkan."

4 Ni bayi, ọjọ ti lọ dię. Mo si maa n saabaa waasu fun bii wakati męrin. Nitorinaa, gęgębi arakunrin ati arabinrin ti o wa ni ęka yii ti fi iręlę fun wa ni aaye, a o ge iyęn kuru ni asalę yii. Bęęni, mo sọ fun Terry, mo ni…. O sọ pe, "Kini … iwọ yoo se fanran oni wakati meji?"

Mo sọ pe, "Rara, Terry; ibi àsè ni eleyi." Mo ni, "Fun bii ọgbọ̀n tabi ogoji isęju, n o ba awọn eniyan sọrọ nipa nkankan ti…. Biotilę ję wipe mo ti gbiyanju ni gbogbo igba, bi mo se mo wipe…."

5 Nigbati mo si ję ọdọmọdekunrin, awọn eniyan maa n jade wa lati feti silę nitori mo ję ọdọmọkunrin oniwaasu, ọdọmọde, ọmọdekunrin. Wọn o si sọ pe, "O dara, Billy Branham….Ẹ mọ, mo ję ọmọde, ti ko lọ si ile-iwe, ti ko si kawe" Wọn yoo jade wa lati gbọ ọrọ mi ti ko dan mọran, èdè Oyinbo ti Kentucky. Nitorinaa … awọn ede abínibí mi ti mo maa n sọ. Bi ọkan ninu awọn ipade ti a se nihin laipę yii, wọn sọ pe, "Gbogbo wa yoo dide duro, a o si kọ orin orilę-ede wa."

Mo dide duro mo si sọ pe, "Fun ile mi ni Kentucky ti o jina rere." Orilę-ede kansoso ti mo mọ niyęn, ni temi o, iyęn ni orin orilę-ede mi.

6 Ni bayi, lęyin ti a ba ti dagba sii, a o wọle wa, o nilati ni ohun ti o ju iyęn lọ. Se ę rii, Pọọlu sọ wipe, "Nigbati mo wà ni èwe, mo maa n sọrọ bi èwe, mo si maa n ronu bi èwe." O n se bi èwe, sugbọn bi o se n dagba sii, nigbanaa iwọ yoo bęrę sii gbe ęsẹ̀ lati kọ ìrìn, iwọ yoo subu, iwọ yoo si tun dide lati gbiyanju leękansii. Lęyinnaa, iwọ yoo … lęyin igba dię, iwọ yoo le rin taara. Ohun ti a si nilati se niyęn gęgębi ọmọ-ogun agbelebu; akoko ti to bayi lati rin taara lọ si ọna ogo.

7 Mo gbagbọ wipe a n gbe ni igba opin itan aye yii. Mo gbagbọ nitootọ wipe bibọ Oluwa sunmọ tosi ju bi a ti ro lọ. Nitorinaa bayi, fun bii ọgbọn isęju akoko yin tabi nkankan, mo fę lati pe akiyesi yin si iwe mimọ kan ti o wu mi lati lo fun koko ọrọ, ki n si tọka si awọn dię sii nibi yii. Mo joko si ile ni ijelo, mo n ronu lori èrò yii. Nigbanaa mo ronu pe, "O dara, n ko mọ, sisọrọ lati inu awọn Iwe Mimọ yii, n o kan mu apakan rę, n o kan … fun awọn isin ké-kè-ké wọnyi, bi iru eyi ti a o ni ni asalę yii. Mo fę sọ ohun kan bi e se n si iwe Orin Dafidi ori

kinni … Orin Dafidi 27, n o ka ẹsẹ marun-un àkọ́kọ́.

8 Mo fẹ sọ eleyi nipa awọn Onísòwò - awọn ẹka Ẹgbẹ Awọn Onisowo ti o Gba Ẹkunrẹrẹ Ihinrere Gbọ. Arakunrin mi Pearry n sọrọ nipa awọn iwe naa ati bẹẹ bẹẹ lọ, ati awọn iwe titun ti wọn ni. Ẹni melo lo ranti nigbati mo se fanran ohun, ti mo si waasu rẹ ni Phoenix nibi, ni ọ̀kan ninu awọn àgọ́-àjọ, lori "Ẹyin Alagba, Akoko Wo Ni?" Bayi, ìbẹ̀rẹ̀ iwe naa niyẹn (se e rii?) nigbati eleyi sẹlẹ.

Isẹ-iyanu ti o n fi idi akọsilẹ Ọrọ Ọlọrun fun wakati yii mulẹ pọ pupọ ju wipe ki nkankan ma sẹlẹ laipẹ yii. A kan … o ti daju ju. Se ẹ rii, awọn nkan ti ẹ…. Yoo jẹ iyalẹnu fun yin lati jẹ ki ẹ mọ wipe … ohun ti o n sẹlẹ gan-an. Boya ọpọlọpọ ẹyin alejo ni ẹ gbọ ti awọn ọkunrin wọnyi dide ti wọn si n sọ awọn ọrọ wọnyi nipa isẹ ohun Ọlọrun ti wakati yii ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ohun ti wọn n sọ ni ileri Ọlọrun fun wakati yii, ti O se ileri ohun ti Oun yoo se, a si rii ti O n fihan nipa Iwe Mimọ, ohun ti O sọ wipe Oun yoo se gan-an ni ọna kannaa. O ti sọ ọ tẹlẹ, o si ri bẹẹ gan-an ni pipe ni gbogbo igba, nitori Ọlọrun ni o n sọ ọ.

9 Ti ẹnikan, n ko bikita ẹni ti o jẹ, yoo ba gbiyanju lati sọ iru asọtẹlẹ bẹẹ…. Aaye kekere bintin ni o wa ti ẹnikan ba sọ fun ọ wipe ohun kan pato yoo sẹlẹ, ati pe yoo sẹlẹ ni igba kan pato, aaye kan ninu miliọnu mẹwa. Lẹyinnaa, ibiti yoo ti sẹlẹ, yoo jẹ aaye ẹyokan ninu miliọnu lọna ọgọrun. Lẹyinnaa, asiko ti yoo sẹlẹ, siwaju ati siwaju. Ati ọna ti yoo gba sẹlẹ ati bi yoo se sẹlẹ, ati bẹẹ bẹẹ lọ, o kọja afinuro. Nigbati a rii ti o pé ni gbogbo igba, a jẹ wipe Ọlọrun ni. A si tun wa pada sinu Iwe Mimọ - o le se ajeji si wa, sugbọn a o tun pada sinu Iwe Mimọ lai tilẹ mọ ibi ti a lee wo, Ẹmi Mimọ yoo si mu jade, yoo si so gbogbo Ọrọ naa papọ, yoo si mu aworan kan jade nibẹ lati fi wakati ti a n gbe ninu rẹ han wa. A n yi awọn igba pada.

10 A ti wà ni igun kan. O rọrun nigbati ẹnikan ba n yi igun - ti kọlekọle kan - yi igun kan ki o si bẹrẹ…. Olukuluku lo le fi biriki lelẹ ni ọgbanran kan, gẹgẹbi igba ti ijọ ẹlẹkọ adamọ kan ba bẹrẹ lati maa yi lọ si isalẹ ipele naa, o dara; sugbọn nigbati ẹ ba de awọn igun nibiti ẹ nilati sẹ ori pada si ọna miiran… Bayi, Ọlọrun ko maa mọ ogiri kan; ile ni O n kọ. Se ẹ rii? Ọpọlọpọ igun ni o si wà lati yí, eyiti O ti sọtẹlẹ ninu Bibeli nihin. Awọn igun wọnyi si ni…. Ẹnikẹni lo lee gbiyanju lati yi igun, sugbọn o nilati wa ni ibamu pelu alakalẹ naa. Ti ko ba ri bẹẹ, a nilati tun wó o lulẹ ni.

11 Nitorinaa a yin Ọlọrun fun oore Rẹ ati idapọ ẹyin eniyan, ati ilẹkun ti Oluwa ti si silẹ fun wa. Ati nipasẹ awọn Onisowo wọnyi…. Mo ti maa n sọ nigbagbogbo wipe n ko gbagbọ ninu…. Mo gbagbọ ninu awọn eniyan ti o wa ninu ijọ ẹlẹkọ adamọ, sugbọn n ko ni akoko ti o to lati gba awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ ni iyanju, nitori olukuluku wọn ti mọ odi yi ara rẹ ka, ati….

O si da bi eni wipe…. Mo gbagbọ wipe ọrọ kekere kan ti Arakunrin Dafidi maa n sọ ni, nipa bi o se n sin awọn pẹpẹyẹ kan, o ni omi yoo sàn wá, ati pe pẹpẹyẹ kọọkan, se ẹ mọ, wọn fẹ ni idapọ pẹlu ara wọn, wọn ko si lee se e nitori a ti mọ odi yi wọn ka. Sugbọn nigbati omi ba kun de oke, yoo kan gbe awọn pẹpẹyẹ naa lefoo kuro ninu ọgba ni. Nitorinaa, mo ro wipe bi o se yẹ ki a se e niyẹn, ki a kan… Omi yoo kun de oke (se ẹ rii?), a si le jade kuro ninu ọgba ki a ni idapọ pẹlu ara wa, se ẹ mọ, ki a ni ojulowo ifẹ Kristi ni ọkan wa.

12 Awọn Onisowo ti o Gba Ẹkunrẹrẹ Ihinrere Gbọ wọnyi ti jẹ ibi itura fun mi, nitori ni ọpọlọpọ igba, mo ni awọn arakunrin, awọn arakunrin ti o dara ninu ijọ ẹlẹkọ adamọ kọọkan ti mo ti ba pade, mo ro bẹẹ, awọn ijọ Alagba, Luther, Onitẹbọmi, Afi-ede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ, orisirisi wọn, Ijọ Ọlọrun, ati Nasareni, ijọ Arinrinajo Iwa Mimọ, awọn ara ti o dara, nibigbogbo…. Sugbọn ni ọpọ igba, wọn ko lee gba mi ni agbegbe wọn, nitori…. Se ẹ rii? Ki i se wipe wọn ko gba a gbọ, sugbọn se ẹ rii, yoo ja wọn kuro ninu ijọ ẹlẹkọ adamo wọn. Nigbati ẹ ba si se iyẹn, o pari niyẹn.

Nihin laipẹ yii, arakunrin ijọ Eleto kan tọ mi wa. N ko ni sọ orukọ rẹ̀, ẹni daradara kan ni. O n kọ iwe kan lori iwosan-lati-ọrun-wa, o si tọ mi wa fun awọn ọrọ kan. A joko a si sọrọ fun igba diẹ. O si wipe, "Ohun kansoso ni a ni lodi si ọ, o n faramọ awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ yẹn ni gbogbo igba.

Mo ni, "Nigbanaa ẹ jẹ ki ijọ Eleto se agbatẹru rẹ; n o wa."

Iyẹn yatọ nigbanaa. Se ẹ rii? O sọ pe, "O dara, emi kọ́ ni ijọ Eleto, mo kan jẹ ọkan lara wọn ni."

Mo ni, "Bi o se ri niyẹn!" Se ẹ rii? "Awọn ni, awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ni o si ilẹkun wọn silẹ." Se ẹ rii? "Awọn wọnyẹn ni mo lee tọ lọ." Iye awọn ti yoo ba si si ilẹkun, eese, a setan lati wọle wa. Gẹgẹbi ninu iwe Ifihan ori kẹta, O sọ pe, "Mo duro lẹnu ilẹkun Mo si n kankun. Bi ẹnikẹni yoo ba silẹkun, Emi yoo wọle wa n o si jẹun." Jesu si niyẹn. Gbogbo wa la mọ wipe Kristi niyẹn. Oun si ni Ọrọ naa. Bẹẹ ni! Oun ni Ọrọ naa.

13 Nitorinaa awọn Onisowo ti o Gba Ekunrẹrẹ Ihinrere Gbọ ti jẹ ibi itura ti a ti lee pejọ pọ. Ko si ijọ kankan ti o se agbatẹru rẹ. Gbogbo wọn lapapọ, awọn ọkunrin ninu awọn ijọ, a si wá papọ ni idapọ kaakiri agbaye, kaakiri, nibigbogbo.

Mo si ti ran wọn lọwọ lati fi ọpọlọpọ ẹka wọn lọ́lẹ̀ kaakiri gbogbo agbaye, ti awọn Onisowo ti o Gba Ẹkunrẹrẹ Ihinrere Gbọ. Mo dupẹ fun anfaani yẹn ti a fi fun mi. Nibẹyẹn, awọn Onisowo ti o Gba Ẹkunrẹrẹ Ihinrere Gbọ yoo se agbatẹru rẹ, nigbanaa gbogbo awọn ijọ yoo fẹ wa lọnakọna. Sugbọn sibẹ, n ko fẹ gbiyanju lati fa ẹnikẹni kuro ninu ijọ wọn. Ẹ saa duro ninu ijọ yin ki ẹ si fọ́n ìmọ́lẹ̀ naa ka. Se ẹ rii? Ẹ jẹ ojulowo Kristẹni; olusọ-aguntan yin yoo mọ riri yin. Ojulowo ẹni mimọ ti o daju, ẹnikẹni ti o gbagbọ ninu Ọlọrun yoo mọ riri iru eniyan bẹyẹn. Bẹẹni!

Bayi, mo dupẹ lọwọ arakunrin ti o wà nibi yii, ati iyawo rẹ, ati ẹka yii, fun anfaani yii. Ọlọrun jẹ ki ẹka yii maa dagba sii. Ki ibukun Ọlọrun wa lori rẹ, ki o si jẹ ohun èlò lọwọ Ọlọrun lati gba ọgọọgọrun awọn eniyan là saaju bibọ Oluwa, ati gbogbo ẹyin ẹ̀ka ti o kù - tabi ẹyin asoju ti o wa nibi lati inu awọn ẹ̀ka ti o kù.

14 Ninu iwe Orin Dafidi…. Bayi, mo fẹ sọrọ lori àkòrí ti o sajeji gan-an ni asalẹ, yii fun igba diẹ. Mo ni awọn ẹsẹ Iwe Mimọ kan ti mo kọ silẹ nihin, mo si ro wipe boya…. Ni alẹ yii, mo fẹ sọrọ lori ohun kan ti o yatọ, sugbọn mo rii wipe ọjọ ti lọ, bẹẹni n ko si fẹ pẹ to bẹyẹn, nitorinaa mo kan sii si ibi yii, mo si ni awọn ẹsẹ Iwe Mimọ diẹ sii. Mo si fẹ sọrọ lori koko ọrọ yẹn, "Ìgbàsókè Naa." Se ẹ rii?

Bayi, a gbagbọ wipe igbasoke yoo wà. Gbogbo Kristẹni ni o gba iyẹn gbọ, iyẹn ni wipe, awọn oluka Bibeli gbagbọ wipe ìgbàsókè yoo wà.

15 Ati ni bayi, lati kà fun … o jẹ ipilẹ, a o ka Orin Dafidi 25 - ẹ jọwọ - Orin Dafidi 27, ẹsẹ 1 - 5.

> *OLUWA ni imọlẹ ati igbala mi; tani emi yoo bẹru? OLUWA ni agbara ẹmi mi; àyà tani yoo fò mí?*
>
> *Nigbati awọn eniyan buburu, ani awọn ọta mi ati awọn abínúkú mi, sunmọ mi lati jẹ ẹran ara mi, wọn kosẹ, wọn si subu.*
>
> *Bi ogun tilẹ dó tì mí, àyà mi ki yoo fò: bi ogun tilẹ dide si mi, ninu eyi ni ọkan mi yoo le.*
>
> *Ohun kan ni emi ntọrọ lọdọ OLUWA, oun naa ni emi yoo maa wa kiri; ki emi ki o lee maa gbe inu ile OLUWA ni ọjọ aye mi gbogbo, ki emi ki o le maa wo ẹwà OLUWA, ki emi ki o si le maa beere ni tempili Rẹ.*
>
> *Nitori ni igba ipọnju, Oun yoo pa mi mọ ninu àgọ́: ati ni ibi ìkọ̀ọ̀kọ̀ àgọ́ Rẹ ni Oun yoo pa mi mọ; yoo si gbe mi ka … ori àpáta.*

Ki Oluwa fi ibukun si kíkà Ọrọ Rẹ̀ yẹn.

16 Bayi loni, a n sọrọ lori koko ọrọ yii…. Ni bayi, awọn kan ninu yin lee tako ọna ti mo gba, sugbọn ẹni melo nihin ni o gbagbọ wipe Bibeli kọ wa wipe igbasoke ijọ yoo wà? Bẹẹni, sà! Bẹẹ ni! Mimu kuro ti ijọ. Boya o jẹ ijọ Eleto, Onitẹbọmi, Alagba, tabi ẹnikẹni ti o jẹ, Afede-ajeji-sẹri-Emi-Mimọ, ìgbalọsoke yoo wà.

Mo si ro wipe ni sisọrọ, n ko sadeedee wa soke nihin lati sọ nkankan ti mo ro lati tẹ awọn eniyan lọrun. N ko fi igba kan jẹbi iyẹn ri. Mo fẹ wá soke nihin ki n si sọ ohun kan bi a se dari mi lati sọ ọ, ti mo ro wipe yoo jẹ iranwọ fun yin, ohun kan ti yoo mu ki ẹ ni iriri sii pẹlu Ọlọrun ti ẹ ba jẹ Kristẹni, ti ẹ ko ba si jẹ Kristẹni, yoo mu oju ara yin ti yin to bẹẹ ti ẹ o di Kristẹni. Eredi yii si ni ọna ti mo n gba gbe ironu mi le lori bi Oluwa ba se dari mi.

17 Bayi, a kilọ fun wa, pe ninu ekọ yii, ni ikẹyin ọjọ, a o kẹ́gàn wa. Ti ẹ ó bá … Ẹ jẹ ki a ka eyinni fun iseju kan. O wa ni Peteru keji, ori kẹta. Ẹ jẹ ki a ka a ni iseju kan ninu eleyi, ori kẹta, ẹsẹ ikẹta ati ikẹrin. Ẹ jẹ ki a woo bi eleyi ba tọ.

> *Ki ẹ ko mọ eyi pe, awọn ẹ̀lẹ́gàn yoo wá ni ikẹyin ọjọ, wọn o maa rin nipa ifẹkufẹ ara wọn,*
>
> *Wọn o si maa wipe, Nibo ni ileri wiwa rẹ gbe wa? … lati igba ti awọn baba ti sun, ohun gbogbo n lọ bi wọn ti wa ri lati igba ọjọ yii wa.*
>
> *Nitori eyi ni wọn mọ̀ọ́mọ̀ se àìfẹ́mọ̀, pe nipa Ọrọ Ọlọrun ni awọn ọrun ti wa lati igba atijọ, ati ti ilẹ yọri jade ninu omi, ti o si duro ninu omi:*
>
> *Nipa eyiti aye ti … o wà nigbanaa, omi bo o, o si segbe:*

18 Bayi, a rii pe idi ti awọn eniyan fi fi ọwọ yẹpẹrẹ mu ọrọ yii, ni wipe wolii naa ti sọ nibi yii wipe ni ikẹyin ọjọ, awọn ẹlẹgan wọnyii yoo wá, wọn o si maa sọ awọn nkan wọnyi. Se ẹ rii? A ti sọ ọ tẹlẹ. Idi ti awọn eniyan se n se bi wọn se n se loni…. Eese, ẹ n reti rẹ dajudaju, nitori Bibeli sọ pe: "Ni ikẹyin ọjọ, wọn o jẹ olóríkunkun, ọlọ́kàn giga, olùfẹ́ faaji ju olùfẹ́ Ọlọrun lọ, ọ̀dàlẹ̀, olùfisùn èké, alainitẹlọrun, olukẹgan awọn ti o dara, wọn ni

afarawe iwa-bi-Ọlọrun, wọn si n sẹ agbara rẹ̀; kuro lọdọ iru awọn eniyan bẹẹ.” Njẹ a le foju sọna fun afarawe otitọ? Dajudaju!

19 Nigbati Mose lọ si Egipti lati da awọn ọmọ Israẹli nídè pẹlu ọ̀pá kan lasan ni ọwọ rẹ fun ìfìdímúlẹ̀, ti Ọlọrun ọrun si ti i lẹyin, o se isẹ iyanu kan. Awọn alafarawe kan si dide lẹyin rẹ̀, wọn n se ohun kannaa ti o se. Se ẹ rii? Bayi, wọn wá lẹyin igba ti Mose ti kọ́kọ́ se e saaju. Nigbanaa, wọn wa, nitori wọn n se ẹ̀dà ohun ti oun ti se, wọn n se afarawe ojulowo. A ri iyẹn. Ati ni bayi, o sọ pe, “O dara, ìgbà ti Mose niyẹn.” Sugbọn Iwe Mimọ kannaa sọ wipe wọn ó tun pada wá ni ikẹyin ọjọ, “Gẹgẹbi Jannesi ati Jambresi se tako Mose, bẹẹni awọn ọlọ́kàn ìtanù ni ti otitọ wọnyi.” Se ẹ rii? Afarawe, orisirisi awọn nkan lati da ọkan awọn eniyan ru.

Nigbanaa, ti igbasoke eyiti o n bọ wa sẹ yii … Ohunkohun ti Ọlọrun ba ti sọ ninu Ọrọ Rẹ̀, nkankan yoo wá lati dàá rú ti wọn ba lee se e. Ipinnu Satani ni lati se iyẹn.

Gẹgẹbi arakunrin lati ibi ipade Las Vegas se sọ, o ni “Aye ni ijọba Satani, ati wipe ibẹyẹn ni olu ile-ise rẹ̀.” Mo mọ̀ wipe Satani ni ọlọrun aye yi. Oun ni o nsakoso gbogbo orilẹ-ede ti o n bẹ labẹ ọrun. Bẹẹ gan lo ri! Satani lo ni aye yi. Sugbọn Jesu yoo gba a. O fi i fun-Un ni ọjọ kan, Oun si kọ̀ ọ́; sugbọn O sọ wipe, nitori O mọ̀ wipe Oun yoo jogun rẹ̀ ni awọn igba ti o n bọ̀.

20 Awọn ẹlẹgan, ẹ jẹ ki a sọrọ diẹ lori ọrọ kan yẹn ki a to tẹsiwaju. Awọn ẹlẹgan - mo n ka iwe-iroyin kan ni bii ọ̀sẹ̀ meji sẹyin ni Tucson nibiti ọkunrin oyinbo kan ni England ti sọ ọrọ kan - o wà ninu awọn àkọlé iwe-iroyin - wipe kikan mọ agbelebu Jesu Kristi Oluwa wa jẹ èké laarin Pilatu ati Jesu, wipe Ó wá lati se … lati kan sọ ara Rẹ̀ di nkankan ni. Kò sì sí ọna ti a fi le sọ fun-un wipe kò ri bẹẹ, nitori a nilati fi gbagbo gba ohun gbogbo ti o jẹ ti Ọlọrun. A nilati gba a gbọ. Bayi, o tẹsiwaju lati se apejuwe bi o se jẹ wipe iyẹn see se.

21 Nihin laipẹ yii, ni orilẹ-ede nla yẹn, London, tabi ni England, nibiti John Wesley ati Charles ati ọpọlọpọ awọn oniwaasu nla ti igba atijọ yẹn, Spurgeon ati gbogbo wọn ti waasu ihinrere ni ọja ounjẹ ẹran ọsin ati kaakiri ibẹyẹn, wọn kọ isẹ́ ohùn Ọlọrun fun ọjọ wọn, ẹ si wo ohun ti wọn da loni. Ibẹ ni Arakunrin Williams ati awọn ti o ku wà ni asalẹ yii. O jẹ ọkan ninu awọn orilẹ-ede ti o rẹ̀yìn julọ ni gbogbo agbaye. Mo ti lọ kaakiri gbogbo agbaye, sugbon n ko mo nkankan ti o ya ọmọ-àlè bii England. Billy Graham sọ nkan kannaa. Koda, o nilati mu iyawo rẹ kuro ni ibiti wọn n gbe awọn ọkọ̀ si, nitori isekuse laarin awọn ọkunrin ati awọn obinrin ntẹsiwaju ni gbangba ni ibi ti wọn n gbe awọn ọkọ̀ si. Nigbati mo wa nibe, n ko ri ohun ti o lee ba eniyan ninu jẹ ju ohun ti o n sẹlẹ ni England, ti o ni anfaani, ti o si jẹ asiwaju gbogbo aye fun atunse nigba kan. O fihan bi o se lee subu to.

Sugbọn se ẹ ri ohun ti o fa iyẹn, isẹ-ohun-Ọlọrun ti o jade lọ nigbanaa, awọn ara England gbiyanju lati di isẹ-ohun-Ọlọrun naa mu fun ọjọ oni. Iyẹn ko lee sisẹ fun ọjọ oni. Ko lee sisẹ.

Bawo ni….

22 Ti Mose ba mu isẹ-ohun-Ọlọrun fun ọjọ Noa wa nkọ. “A o kan ọ̀kọ̀ oju omi kan, a o si la ori odò Nile kọjá?” Kì bá tí sisẹ. Bẹẹ naa ni isẹ-ohun-Ọlọrun fun ọjọ Jesu ko lee sisẹ pẹlu Mose. Bẹẹ naa ni isẹ-ohun-Ọlọrun fun ọjọ Wesley ko lee sisẹ ni igba Luther, tabi ti Luther ni igba Wesley. Loni pẹlu, atunse nla wa ti o kẹyin ni ijọ Afèdè-àjèjì-sẹ̀rí-Ẹmi-Mimọ. Loni pẹlu, a ti nkuro ninu iyẹn, isẹ-ohun-Ọlọrun fun akoko ijọ Afèdè-àjèjì-sẹri-Ẹmi-Mimọ ko lee papọ mọ eleyi, nitori ọjọ miiran ni. Gbogbo rẹ jẹ Ọrọ Ọlọrun, sugbọn ó n kọ ilé ni. Gẹgẹ bii ẹsẹ̀, apá, o n bọ wa sókè, o n di iyawo fun ìgbàsókè. Se ẹ rii, ẹ mase mu awọn eniyan naa kuro ni àayè wọn nibẹyẹn; wọn gbé ìgbé-ayé isẹ-ohun-Ọlọrun fun ọjọ wọn. Gbogbo awọn ti ó jẹ́ ara iyawo ninu wọn ni yoo jade wá. O dabii ìyè ti o n la inu pòpórò ọkà kọja. Yoo fi àlìkámà silẹ - ani sùkù, sugbọn àlìkámà naa yoo mọ ara rẹ̀, gẹgẹbi hóró ọkà ti ó bọ́ sinu ilẹ̀.

23 Nihin laipẹ yii, mo n ka iwe kan ti ara Germany kan kọ fun àtakò; ó sọ pe, “Ninu gbogbo awọn gbawèrè-mẹ́sìn ti o wà laye, William Branham ni ọ̀gá gbogbo wọn.” O ni, “Koda, kò jẹ́ nkankan bikose… Òpìdán ni. O n se awọn nkan wọnyi….” Se ẹ rii, ọkunrin yẹn kò mọ̀….

Nigbanaa, ọkunrin yẹn jẹ alatako. Kò tilẹ gbàgbọ́ ninu Ọlọrun. O ni, “Ọlọrun ti o joko soke ni igba Okunkun Biribiri, ti o si káwọ́ gbera, ti o si nrẹrin nipa awọn Kristẹni ti ó jẹ ìyà, o si yẹ ki awọn ọmọ ẹyin Rẹ̀ jẹ - awọn ìyá pẹlu awọn ọmọde ati ohun gbogbo, Ó sì jẹ́ ki awọn kiniun jẹ wọ́n, kò tilẹ gbé ọwọ́ kankan.” Se ẹ ri ibi ti ọkan ẹran ara ronu lọ, ti ó jẹ wipe iwe kika ati ohun gbogbo ko lee ri iran naa?

24 Hóró ọkà yẹn nilati bọ silẹ.

Bi Jesu se nilati subu ki Ó si tun dide, bẹẹ ni ijọ Pẹntikọsti nilati subu. Ó nilati wọ inu ilẹ lọ, awọn igba Okunkun Biribiri. Gbogbo alikama, gbogbo hóró ọka ti o ba wọ inu ilẹ lọ, ó nilati duro ninu igba okunkun yẹn lati lee hù jade. Sugbọn ó bẹrẹ sii hù ninu Martin Luther. Ó jade wá nipasẹ Wesley, titi ti o fi dé ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ; bayi o ti lọ si horo ọkà padà. Ati ni bayi, awọn ìgbékalẹ̀ ìlànà ijọ ẹlẹkọ adamọ ti wọn ti fi sẹyin, awọn yẹn jẹ pòpórò. Ko ju bẹẹ lọ. A nilati dá ina sun-un, ìlànà ijọ ẹlẹkọ́ adamọ. Sugbọn ojulowo hóró alikama

ti o jade kuro ninu ọkọọkan awọn atunse yẹn ni a o gbà lọ soke ninu iyawo. Apapọ gbogbo wọn ni o di iyawo.

25 Bayi, a rii ni England wipe wọn se afarawe kíkàn mọ́ agbelebu laipẹ yii, ọpọlọpọ awọn eniyan yẹn, awọn ọmọde kan pẹlu irun gígùn ati bẹẹ bẹẹ lọ, ti wọn n kigbe … wọn pe Jesu ni "Daddy-O" ati iru nkan bẹẹyẹn. Ẹgbin lasan.

Bayi, o sọ pe, "Sebi London, England niyẹn." Ẹ wo ohun ti o wà ninu iwe iroyin ni ọ̀sẹ̀ to kọja nihin ni Amerika. Ẹnikan ti o gba oye dokita ninu ẹkọ ẹ̀sìn lati ile-iwe kan ti o dara, sọ wipe kikan mọ agbelebu jẹ èké, o ni Jesu kan gbiyanju lati se ara Rẹ bẹyẹn ni, wipe O ti mu igbo mándrékì, ati wipe…. A rii ninu Genesisi, nibiti a ti sọrọ nipa rẹ̀. Koríko kan bi igbó mímu ni tabi iru nkan yẹn. A maa n rii ni awọn Orilẹ-ede Ila Oorun agbaye nibẹ. Ti o ba si mu u, yoo mú ki o sùn, boya ninu … bi ẹni wipe o ti kú, iwọ yoo subu lulẹ, ohun gbogbo fun bii ọjọ meji tabi mẹta lẹẹkannaa.

26 O ni nigbati wọn fun-Un ni ọti kíkan ati òróǹro, o seese ki o jẹ ewe mándrékì ni. Nigbati wọn si see, wọn fun-Un ni iyẹn; O si lọ, o subu lulẹ bi ẹnipe O ti kú. Wọn fi I sinu iboji, wọn si dá a dùbúlẹ̀ sibẹ. Ati lẹyin ọjọ meji tabi mẹta, dajudaju, O pada ji, ara Rẹ si le. O ni, Ó lọ si India, O si ku nibikan, iku lasan. Ó n gbiyanju lati dá ẹ̀sìn èké kan silẹ. Lakọ́kọ́ na, alatako yẹn…. Kilo n se awọn eniyan? Se ẹ rii? Ọjọ ti a n gbé inu rẹ̀ ni, awọn ẹlẹgan (se ẹ rii?) ọjọ ti a nilati mú asọtẹlẹ sẹ.

27 Ọlọrun pín Ọrọ Rẹ si ìran kọọkan. Ọkọọkan awọn ìran yẹn si nilati fi iyẹn han. O si ti yan awọn eniyan kan tẹlẹ fun ìran yẹn lati mu Ọrọ yẹn sẹ. Igbagbogbo ti O ba pin Ọrọ Rẹ̀. Ó ti yan ẹnikan fun-un. Nigba ti O yan àkókò Mose, O yan Mose si i. Nigbati O yan àkókò kan fun bíbí Ọmọ Ọlọrun, O yan-An si i. Ni iran kọọkan ni O ti yan awọn ẹni tirẹ ti O ti yan tẹlẹ. Bi Bibeli se sọ, ko si ohun…. Ti Ọlọrun bá jẹ́ alailopin, alagbara, ti O ni gbogbo ipa, ti O wà nibi gbogbo, ti O si mọ ohun gbogbo, a jẹ wipe, Ó mọ ohun gbogbo lati ibẹrẹ. Nitorinaa, O mọ… Ko si ohun kan ti o daru; àwa la kàn n rò bẹẹ. Ohun gbogbo n lọ….

Ẹ pada wo inu Ọrọ Rẹ̀ ki ẹ si ri ohun ti O n se, nigbanaa a o loye.

28 Bayi, saa ronu. Lakoko na, iba se wipe oniwaasu yẹn ronu ni, nigbati wọn fi ọti kikan ati òróǹro yẹn si ẹnu Rẹ, O tu ú jade ni. Kò tilẹ mu u rara. Se ẹ rii? Awọn ẹlẹgan ni o kàn n dide. Ohun miiran, bawo ni Jesu ti Nasareti yii, bawo ni igbe-aye Rẹ se bá gbogbo asọtẹlẹ Majẹmu Laelae mu? Bawo lo se le ri bẹẹ? Ko le ri bẹẹ lai jẹ wipe Ọlọrun ti yan-an tẹle. Igbe-aye Rẹ ba gbogbo asọtẹlẹ Majẹmu Laelae mu. Ohun miiran, iba se wipe awọn ọmọ ẹyin dọgbọn si I bẹyẹn, eese ti ọkọọkan wọn fi jẹ ajẹriku? Aposteli Peteru paapaa sọ wipe, "Ẹ da ori mi kodò; n kò yẹ lati kú bii Tirè." Wọn mu Anderu, wọn si kọ ori rẹ sẹgbẹ lori agbelebu. Olukuluku wọn lo fi ẹjẹ rẹ̀ se èdídí ijẹri wọn. Wọn gba A gbọ, wọn si fẹran Rẹ, wọn si fi ẹmi wọn lelẹ fun-Un. Ti O ba jẹ èké ni, bawo ni wọn iba ti se iyẹn? Se ẹ rii, ìmúlò ti ẹ̀mí, kò yé awọn eniyan.

29 Ẹni nla kan wá sibi laipẹ yii, Rabbi nla kan, ti o kọwe wipe nigbati Mose n la Okun Pupa kọja, o ni, "Kii se omi gan-an; wipe omi yẹn kò ga soke bi odi." O ni, "Ohun ti o jẹ, ní odikeji Okun Pupa lọhun, wipe igbo pankẹ́rẹ́ nla kan wà nibẹ, o si la omi kọja - pankẹ́rẹ́, igbo pankẹ́rẹ́ ti omi. Ko si omi nibẹ, sugbọn ọpọlọpọ igbo pankẹ́rẹ́ kan ni, alagbalúgbú igbo pankere kan ni wọn là kọja." Ọpọ awọn alufaa ni o si gba iyen gbọ, ti wọn si gba a.

Nihin laipẹ yii nigbati ẹniti o kọ́kọ́ fò kuro ninu aye yii lọ soke, o pada wa, kò si rí nkankan ti o jọ Ọlọrun. Iyẹn yí awọn oniwaasu paapaa lọkan pada. Wọn ro wipe Ọlọrun n gbe ibikan loke nibẹyẹn, bii aadọjọ maili soke.

30 Kinla, bawo…. Ẹkọ ati ọgbọn aye yii ti sọ ijọ di kiki ekisa lasan.

Ẹkọ, ati ìlànà ẹkọ, imọ ijinlẹ, ati ọlaju jẹ ti esu. Ọlaju ti esu ni. Bibeli sọ bẹẹ. Ọlaju tiwa ti o n bọ ko ni ni nkankan se pẹlu ọlaju eleyi rara. Ko ni nkankan se pẹlu rẹ rara. Yoo jẹ́ ọlaju ti o yatọ. Ninu ọlaju ati aye imọ ijinlẹ eleyi, a ni…. Bi a se n ni imọ ijinlẹ sii, bẹẹ naa ni a n wọ inu iku lọ sii, ati awọn nkan, ati awọn pàkúté ikú, ati ohun gbogbo. Ninu ọlaju titun naa, ki yoo si iku, aisan, ibanujẹ tabi irora. Se ẹ rii? Ko ni si ẹyọkan nibẹ. Nitorinaa a nilati pa ọlaju eyi run, nitori ti esu ni.

31 A ri i ni Genesis 4 wipe awọn eniyan Kaini ni o bẹrẹ ọlaju, wọ́n n kọ́ awọn ilu, ilu nla, ati bẹẹ bẹẹ lọ, ati awọn ohun èlò orin, wọn si di … ati imọ ijinlẹ. Awọn eniyan si njinna si Ọlọrun sii, sibẹ wọn jẹ ẹlẹsìn. Sugbọn nigbati awọn eniyan Sẹti de, wọn bẹrẹ si i pe orukọ Oluwa. Ah, ti a ba nsọrọ nipa ohun ayinike.

N kò wá sibi lati ba ẹnikẹni ninu jẹ, tabi lati sọ ohun kan nipa ijọ kan. Ti o ba sì wà nibi ti o jẹ ọmọ ijọ yii, n kò sọ eleyi lati bà ọ ninu jẹ, nitori awọn eniyan rere wa nibẹ bi wọn se wà ni awọn ijọ ti o kù. Sugbọn mo n ka ni Shreveport ni ọsẹ to kọja nibiti ijọ Katoliiki ti sọ ọrọ kan. A si ri ibiti gbogbo wọn ti n papọ bayi ni ibi igbimọ ijọ agbaye naa ati bẹẹ bẹẹ lọ, ti wọn si n se imusẹ ohun ti Bibeli sọ wipe wọn yoo se gan. Bẹẹ gan lo ri.

32 Bayi, a rii ti wọn sọ wipe, "Eese, Bibeli, awọn kan lara awọn ijọ Alatako Katoliiki fẹ di Bibeli yẹn mu. Wọn

ni, ”Bibeli kò jẹ nkankan bikose iwe kan lasan, itan ti ijọ, wọn ko si ni I ninu iwe akọsilẹ bikose bii ọtaleerugba o din mẹwa ọdun sẹyin. O ti maa n jẹ ijọ nigbagbogbo.“ Wọn ni ijọ ni, ki i se Bibeli, wipe Bibeli kan jẹ itan ohun ti ijọ se.” Iru irọ wo ni eleyi. Ẹ gbọ, a ti ni Bibeli fun ẹgbẹrun ọdun mẹta. A kọ Majẹmu Laelae ninu Iwe Mimọ fun ọpọlọpọ ọdun ki Kristi to de. O kàn jẹ arekereke esu.

33 A si rii lọjọ oni, nigbati wọn nkẹgan Bibeli, ti wọn n fi I se ẹlẹya, ti wọn si ngbiyanju lati ti I sita…. Ọlọrun nilati dá ijọ lẹjọ nipa nkankan. Kò lee jẹ olododo. Wọn kò lee lọ si oju popo ki wọn si mu mi wipe mo n sare ọgbọn maili ni wakati kan dipo ogun maili, ayafi ti nkankan ba wa nibẹ lati sọ fun mi wipe ogun maili nikan ni ere ti aaye gba mi lati sa. O nilati wa nibẹ. Ọlọrun yoo si da ijọ lẹjọ … yoo da awọn eniyan lẹjọ ni ọjọ kan. A mọ iyẹn. Idajọ kan n bọ. Ti yoo ba da a lẹjọ nipa ijọ Katoliiki, èwo ninu awọn ijọ Katoliiki? Ti yoo ba se idajọ nipa ijọ Eleto, a jẹ wipe awọn Onitẹbọmi ti sọnu niyẹn. Ti O ba se idajọ nipa awọn ẹlẹkọ-adamọ ẹnikan-ninu-ọlọrun kan, njẹ awọn ẹlẹkọ-adamọ ẹnimeji-ninu-ọlọrun kan ti sọnu niyẹn. Se ẹ rii? Kini yoo fi se idajọ? O ni Oun yoo se idajọ nipa Kristi, Kristi si ni Ọrọ naa. Nitorinaa, Ọrọ Ọlọrun ni Ọlọrun yoo fi se idajọ. “Ni atetekose ni Ọrọ wa, Ọrọ si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa. Ọrọ naa si di ara o si n gbe laarin wa… Ọkan naa lana, loni ati titi laelae.” Se ẹ rii? Nitorina yoo se idajọ nipa Ọrọ Rẹ̀.

Ni bayi, a rii wipe ni ọjọ oni, nigbati wọn ngbiyanju lati ti Bibeli sita, ki wọn si gba ijọ…. Bibeli, wọn ko fẹ́ ẹ - ijọ - ki wọn baa le se ẹkọ-adamọ tabi ohunkohun miiran ki wọn si maa rin nipa rẹ̀.

34 Njẹ bi mo se n sọrọ ni alẹ ijelo ni Shreveport nibi àsè irekọja, nigbati wọn yoo pa aguntan ìrúbọ yẹn, ko gbọdọ si ìwúkàrà laarin wọn ni gbogbo ọjọ mejeeje. Ko si iwukara, ko si akara wiwu. Ohun gbogbo gbọdọ jẹ alaiwu. Iyẹn se apẹẹrẹ awọn ìgbà ijọ meje ti a ni ninu iwe yẹn nibi. Ko sì sí iwukara. Kini - ohun kan dapọ pẹlu rẹ̀. A si ti da ẹkọ adamọ, ati ijọ ẹlẹkọ adamọ, ati ohun gbogbo miiran pọ pẹlu Ọrọ naa, a si tun ngbiyanju lati pe E ni Ọrọ naa. Ko gbọdọ si iwukara ni ọjọ mejeeje naa.

35 Ki tun ni, ohun ti ẹ jẹ loni, mase gbiyanju lati fi pamọ di ọla, ẹ fi ina sun-un ki ilẹ to mọ, nitori isẹ-ohun-Ọlọrun miiran n bọ ati ohun titun.

Se ẹ rii, wọn ngbiyanju lati fii pamọ di ọjọ keji. Isesi ijọ si niyẹn. Ti isọji kan ba bẹrẹ, ohun ti yoo sẹlẹ ni wipe, laarin ọdun mẹta, wọn yoo sọ ọ di ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ. Ijọ ẹlẹkọ adamọ yoo bẹrẹ ẹgbẹ́ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ. Sugbọn njẹ ẹ ti kiyesii, eleyi ti n gbilẹ fun ogun ọdun bayi, ko si si ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ. Ko si lee si laelae! Opin niyi. Alikama ti pada di alikama lẹẹkan sii. Alikama ti pada si horo rẹ. Èepo ti si kuro lara re. Alikama si nilati duro niwaju oorun ki o baa le pọ́n.

36 Njẹ ko sàjèjì wipe laipẹ yii ní Ẹkun Ila Oorun, okunkun biribiri kan sẹlẹ. Ko ye wọn. Okunkun bo Texas mọlẹ ni ọ̀sẹ̀ to kọja. Ko lee ye wọn. Se ẹ ko mọ wipe ami niyẹn ni? Se ẹ ko mọ wipe awọn orilẹ-ede ti n subu? Israẹli ti wà ni ilẹ-ini rẹ̀, awọn ami wọnyi si n fihan wipe a ti wa ni opin! Akoko kannaa ti o nsokunkun, se ẹ ko mọ wipe ami ti wolii naa sọ niyẹn wipe, “Sugbọn imọlẹ yoo wa ni akoko asalẹ,” wipe imọle kan yoo tan jade ni akoko asalẹ nigbati awọn okunkun ati awọn nkan yoo maa se bi wọn se n se bayi.

37 Ẹ wo bi o se sokunkun.

Poopu sẹ̀sẹ̀ wa sihin ni. Ẹ ranti ni ile-ijọsin nigbati awọn - ẹ ní awọn fánrán ohùn - mo lero wipe gbogbo yin ni ẹ gba wọn - bi Oluwa se fihan nibẹyẹn ni ọjọ yẹn ninu ile-ijọsin, ibi gan ti awọn igba ijọ meje wọnyen yoo wà gan-an, ati bi wọn yoo se wa. Mo si yà wọn si oju patako nibẹyẹn, awọn igba ijọ meje ti ẹ ri ti a yà sinu iwe. Ẹmi Mimọ kannaa si sọkalẹ ninu ọ̀wọ̀n ina nla, O si lọ si ẹ̀yìn, lara ògiri, O si yà wọn jade funra Rẹ̀, nigbati awọn eniyan bii ọ̀ọ́dúnrún tabi irinwo joko ti wọn si n wo o. Kete ti poopu gbera lati wa sihin, osupa sokunkun, wọn si ya aworan rẹ, bakannaa bi a se ya a si ori pẹpẹ nibẹ. Bayi, o rin irin ajo rẹ wa sihin ni ọjọ kẹtala, o gbe igbesẹ mẹtala, o fun ẹni mẹtala ni akara idapọ, si orilẹ ede ti o jẹ nọmba kẹtala, okunkun si n bolẹ nibi gbogbo. Se ẹ ko ri ibi ti a wà ni? A ti wà ni ìgbà ìkẹyìn.

“Awọn ẹlẹgan yoo dide ni ikẹyin ọjọ, wọn o maa wipe, 'Ko si iyatọ si bi o se ri tẹlẹ, si igba ti awọn baba ti sun.'” Sugbọn nigbati ẹ ba ri awọn nkan wọnyi ti o n sẹlẹ, ẹ gbe ori yin soke; ẹ mura silẹ; nkankan lee sẹlẹ nigbakuugba. Kristi n bọ wa fun ijọ Rẹ.

38 Bayi, wọn ko gba a gbọ, nitori o jẹ́…. Wọn ko mọ wipe awọn ni o n mu Iwe Mimọ se. Awọn eniyan naa ko mọ wipe nipa síse awọn nkan wọnyi, ati nipa sísọ awọn nkan wọnyi, wọn n mu Iwe Mimọ se. Bawo ni Káyáfà olori alufaa ati gbogbo awọn alufaa yẹn ni ọjọ yẹn ti o n kẹgan ti wọn si n fi I se yẹyẹ - wọn kò mọ̀ wipe Ọlọrun kannaa ti wọn n kọrin nipa Rẹ, “Ọlọrun mi, eese ti Iwọ fi kọ̀ mí silẹ? [Orin Dafidi 22] Ọwọ mi ati ẹsẹ mi, wọn lu ú….” Wọn n kọ orin yẹn ni tẹmpili, Oun si n ku lọ lori agbelebu, wọn ko mọ wipe awọn n se e. Jesu paapaa gbadura, “Baba, dariji wọn; wọn ko mọ ohun ti wọn n se.” Nitori Iwe Mimọ ti sọ tẹlẹ wipe wọn yoo fọju.

39 Njẹ ẹ mọ wipe asọtẹlẹ ti wà, wipe awọn ijọ ti o tako Katoliiki ati Katoliiki paapaa yoo fọju ni ikẹyin ọjọ?

Bẹẹ naa ni Iwe Mimọ, Kristi wa ni ita, O ngbiyanju lati wọle? “Nitori iwọ wipe emi ni ọrọ̀, emi ko si se alaini ohunkohun, iwọ kò sì mọ̀ wipe osi ni iwọ, ati àre, ati talaka, ati ẹni ihooho, ati afọju, iwọ kò sì mọ̀ ọ́!” Ifihan 3. Bi o se ri niyẹn, wọn tun pada sinu ifọju lẹẹkan sii, wọn n tẹ awọn nkan ti Ọlọrun mọle bi ẹni wipe ko jẹ nkankan si wọn, wọn n kẹgan, wọn si n fi i se ẹlẹya; ohun ti Bibeli sọ niyẹn.

40 Sugbọn si ijọ, iyawo, igbasoke jẹ ifihan si i. A fihan fun-un, wipe ifihan naa, iyawo Kristi tootọ yoo maa duro de ifihan igbasoke naa.

Bayi, ifihan ni, nitori ifihan jẹ igbagbọ. O kò lee ni ifihan laijẹ wipe o wá nipa igbagbọ. Igbagbọ jẹ ifihan, nitori o jẹ ohun kan ti a fi han fun ọ. Igbagbọ jẹ ifihan. Igbagbọ jẹ ohun kan ti a ti fi han fun ọ bi a se fi han fun Abrahamu, ti o fi lee pe ohunkohun ti o lodi si ohun ti a ti fi han fun-un bi ẹni wipe ko si. Bayi igbagbọ…. Ohun ti igbagbọ jẹ niyẹn, ifihan Ọlọrun ni. A kọ́ ijọ le ori ifihan, gbogbo ara naa.

41 Nihin ni ọ̀sẹ̀ diẹ sẹyin, mo n ba oniwaasu daradara kan, ti ijọ Onitẹbọmi sọrọ. O tọ mi wa lati ba mi jiroro. O ni, “Mo fẹran rẹ gẹgẹbi eniyan, sugbọn,” o ni, “ohun gbogbo ti daru mọ́ ọ loju.”

Mo sọ pe, “O dara naa, jọwọ tọ́ mi sọna…” bayi, o sọ pe … “pẹlu Iwe Mimọ.”

O ni, Arakunrin Branham, a ko ni lee mu awọn nkan tọ́, ayafi igba ti a ba to mu gbogbo ọrọ papọ, ọrọ lori ọrọ, lori ọrọ, ni ibamu pẹlu ede Giriki ati bẹẹ bẹẹ lọ.“

Mo sọ pe, “Ah, alagba, ẹ mọ ju iyẹn lọ.” Mo ni, “Ni Igbimọ Nikia paapaa, ni ọjọ ti o ti pẹ to iyẹn, ọ̀ọ́dúnrún ọdun lẹyin iku Kristi, wọn sì n ba ara wọn jiyan lori wipe ọmọwe Gíríkì wo ni ó tọ́nà. Ẹ ko lee…. Ifihan ni. Gbogbo nkan naa jẹ….”

O ni, “Emi ko lee gba ifihan.”

Mo ni, “Bawo ni o se fẹ gba Kristi nigbanaa?”

O ni, “Eese, Bibeli sọ pe, ”Ẹniti o ba gba Jesu Kristi gbọ, ni ìyè ayeraye.“

Mo ni, “Otitọ niyẹn. O tun sọ wipe ko si ẹni ti o lee pe Jesu ni Kristi ayafi nipa ifihan ti Ẹmi Mimọ, ti a fi han fun-un.” Se ẹ rii? Bi o se ri niyẹn, o tun pada wa, o tun pada sori ifihan. A ni lati fi i han.

42 Ninu Bibeli…. Kaini ati Abẹli kò ni Bibeli lati ka, sugbọn a fi han fun Abẹli nipa igbagbọ, tii se ifihan. Abẹli ru ẹbọ si Ọlọrun, eyiti o dara ju ti Kaini lọ, ti Ọlọrun si jẹri rẹ̀ wipe o jẹ olododo. Nigbati a beere lọwọ Jesu ni Mattew 16:17 ati 18…. A kò ni àkókò lati ka a, sugbọn ti ẹ ba fẹ kọ ọ silẹ. O ni, “Ta ni awọn eniyan n fi Emi, Ọmọ Eniyan pe?”

Ọkan ninu wọn sọ pe, “Iwọ ni Mose, Elijah, tabi ẹnikan.”

O wipe, “Sugbọn ta ni ẹyin n fi Mi pe?”

O ni, “Iwọ ni Kristi naa, Ọmọ Ọlọrun Alaaye.”

O ni, “Alabukunfun ni iwọ, Simoni ọmọ Jona, nitori ẹran ara ati ẹ̀jẹ̀ kò fi eleyi han fun ọ; Baba Mi ti n bẹ ni ọ̀run ni o ti fi han ọ. Lori apata yi (Ifihan ti ẹ̀mí nipa ẹniti Ọlọrun jẹ, ẹniti Jesu jẹ, Oun si ni ifihan Ọlọrun, Ọlọrun ti a sọ di eniyan, ti a si fihan fun aye. O wà ninu aye; Ọlọrun wa ninu Kristi, O n ba aye laja sọ̀dọ̀ ara Rẹ, O n fi ohun ti Ọlọrun jẹ han ninu ẹran ara.) … Iwọ ni Kristi naa, Ẹni-ami-ororo naa, Ọmọ Ọlọrun.”

O ni, “Ẹran ara ati ẹjẹ kò fi eleyi han ọ, bikose Baba mi ti n bẹ ni ọ̀run ni o fi eleyi han ọ. Lori apata yii ni Emi yoo kọ ijọ Mi le (ifihan Ọrọ naa ni akoko Rẹ), Emi yoo kọ ijọ Mi, ẹnu ọna ọrun apaadi ko si lee bori Rẹ.”

43 Iwe Ifihan ni iwe ti o kẹyin ninu Bibeli. A fi pamọ fun awọn alaigbagbọ. Nibẹ Bibeli sọ ni ori kejilelogun, “Ẹnikẹni ti o ba mu ọrọ kan kuro tabi ti o fi ọrọ kan kun-un, Emi yoo mu ipin rẹ kuro ninu iwe iye.” A wa rii wipe awọn onigbagbọ nikan ni a fi fun. O si si iwe Ifihan, o si fi ẹniti o ni gbogbo iwe yii han (Ẹniti a o maa wo bii Alfa ati Omega, lati Gẹnẹsisi de Ifihan, Jesu Krsiti kannaa ninu gbogbo rẹ), O si fi ẹkunrẹrẹ ijinlẹ ara Rẹ hàn ati awọn ètò Rẹ fun awọn igba ijọ Rẹ ti o n bọ, a si fi èdídí meje dí i sinu rẹ.

44 Bayi, a kọ iwe naa, sugbọn ẹ ranti, a fi edidi meje di i. A ko si gbọdọ si awọn edidi mejeeje yi, Ifihan 10, titi di igba didun angẹli ti o kẹyin lori ilẹ aye, Ifihan 10:7. Se ẹ rii? “Ati ni ọjọ didun isẹ-ohun-Ọlọrun ti angẹli ti o gbẹyin, angẹli keje, ijinlẹ Ọlọrun yoo pari ni iran yẹn.” Iran ti a si n gbe inu rẹ niyẹn.

Gbogbo wa ni a mọ wipe a ngbe ni igba Laodikea. Ko lee si iran miiran lẹyin rẹ; ko le ri bẹẹ. Nitorinaa a n gbe ni iran Laodikea, awọn edidi meje wọnyi ti o di iwe naa mu jẹ ijinlẹ si awọn eniyan, yoo di sisi ni ọjọ naa. Ohun ti O sèlérí niyẹn. Bayi, ki yoo jẹ ohunkohun yatọ si Ọrọ naa, nitori ẹ ko lee fi kun Ọrọ naa tabi ki ẹ yọ kuro ninu Rẹ. O nilati maa jẹ Ọrọ naa nigbagbogbo. Sugbọn ifihan yẹn ni lati fi otitọ rẹ han, ohun ti o jẹ, lati

jẹ ki o bá iyoku Iwe Mimọ mu. Nigbanaa Ọlọrun yoo fi han wipe otitọ niyẹn.

45 Se ẹ rii, Ọlọrun kò nilo olutumọ kankan. Oun ni Olutumọ ara Rẹ. O maa n se itumọ funra Rẹ nipa mimu awọn nkan ti O ti sọ pe yoo sẹlẹ sẹ. Bii ni atetekọse, O sọ pe, “Jẹ ki imọlẹ ki o wa!” imọlẹ si wa. Iyẹn ko nilo titumọ. A fi i han.

Bayi, O sèlérí awọn nkankan ni ikẹyin ọjọ yii ninu Iwe Mimọ. Eese, o si wa nibẹ. Bi Jesu se jẹ Ọmọ Ọlọrun niyẹn. O sèlérí lati ran-An. Nigbati O wá lori ilẹ aye ti awọn eniyan kò si lee gba A gbọ, O ni, “Ẹ wa inu Iwe Mimọ, nitori ninu wọn ni ẹ rò pe ẹ ni iye ainipẹkun; awọn ni o si n jẹri Mi. Ti Emi ko ba se awọn isẹ Baba Mi, ẹ mase gba Mi gbọ nigbanaa. Sugbọn ti ẹ ko ba lee gba Mi gbọ, ẹ gba awọn isẹ ti Mo n se gbọ; nitori wọn n jẹri ẹniti Mo jẹ.”

46 O dara nigbanaa, ni igba Wesley, awọn isẹ ti o se jẹri ẹniti o jẹ. Ni igba Luther lori atunse, eese, dajudaju o jẹri ẹniti o jẹ. Ni igba awọn Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ, imubọsipo awọn ẹbun, idapada awọn ẹbun, ifedefọ, ati lílé awọn emi esu jade, ati awọn ẹbun, o jẹri. Kò si àwàdà nipa rẹ̀.

Awọn eniyan sọ wipe nigbati ó kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀…. Mo ka awọn iwe nipa itan ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. Wọn ni, “Ko lee pẹ titi; ina naa ko ni pẹ ku.” O si n jo bayi. Kini idi? Idi ni wipe ẹ kò lee pa ina naa laelae. Ọlọrun sọ wipe yoo wa nibẹ. Apakan Ọrọ yẹn ni, ẹ ko si lee pa ina naa… nigbati a ba si n pe iyawo jade, bawo ni ẹ se fẹ pa ina naa? O jẹ isipaya ifihan Ọrọ naa ti a sọ di otitọ. A si n gbe ni ọjọ yẹn. Iyin ni fun Ọlọrun! Ifihan ti ijinlẹ ara Rẹ.

47 Bayi, igbasoke kan wa fun, igbasoke ti a n sọ nipa rẹ yi wa fun iyawo nikan. Ẹ ranti, Bibeli wipe, “Awọn òkú ti o kù kò si wa laaye fun ẹgbẹrun ọdun.” Igbasoke nla yii…. Ti ko ba si igbasoke, ẹyin ọ̀rẹ́, nibo ni a wà? Kini a o se? Iran wo ni a n gbe inu rẹ? Ileri wo ni a ni? Igbasoke yoo wa o. Bibeli sọ wipe yoo wa; yoo si wa fun awọn ayanfẹ nikan, ayanfẹ obinrin naa, iyawo ti a fa jade ni iran yii, eyinni ijọ.

Ọrọ ti a n pe ni ijọ tumọ si “pe jade kuro.” Gẹgẹbi Mose se pe orilẹ-ede kan jade kuro ninu orilẹ-ede kan, Ẹmi Mimọ n pe iyawo jade kuro ninu ijọ kan. Ijọ jade kuro ninu ijọ, awọn ẹnikọọkan lati inu ijọ ẹlẹkọ adamọ lati di iyawo, igi iyawo, o wa ninu fanran ohun, igi iyawo. Iyawo ti o n jade, ti a pe…. Iyẹn si ni igi iyawo … iyawo, oun ni yoo lọ ni igbasoke, iyẹn nikan, ko si ohun miiran bikose iyawo, awọn ayanfẹ ti Ọlọrun ti mọ tẹlẹ lati atetekọse, iru ẹmi ti Baba.

Ẹ jẹ ki n duro nihin fun isẹju kan, ti…. Ara mi ko saa balẹ, mo nronu wipe n o da yin duro pẹ.

48 Sugbọn ẹ kiyesii; ẹ wo o! Ọkọọkan ninu ẹyin eniyan, njẹ ẹ mọ wipe ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin ki a to bi yin, ẹ ti wa ninu baba yin gẹgẹbi iru? Bẹẹ ni! Iru ọgbin kan wa ninu baba yin, o n wá lati ọdọ akọ, kii se abo. Se ẹ rii? Abo ni o n pèsè ẹyin, ilẹ ọ̀gbìn, sugbọn iru maa n wa lati ọdọ baba.

Bayi, o sọ wipe ninu baba mi tabi ọmọkunrin mi ti o joko sihin yi. Nigbati mo jẹ ọmọ ọdun mẹrindinlogun, ọmọkunrin mi wà ninu mi. N kò mọ̀ ọ́, sugbọn o wà nibẹ. Bayi, nipasẹ ilẹ ọgbin, nipa igbeyawo mimọ, o wá di aworan mi. Mo mọ̀ ọ́; mo le ni idapọ pẹlu rẹ̀. O si wá nigbati akoko to.

49 Bayi, bẹẹ ni iwọ naa wa ninu…. Ti o bá ni ìyè ainipẹkun, o wà ninu Ọlọrun saaju ki a to da aye. O jẹ apa kan, ọmọ Ọlọrun, èrò Ọlọrun. Ó mọ akoko naa gan-an ti iwọ yoo wa. Ó yan ọ tẹlẹ si iran yẹn lati sẹlẹ, ko sì sí ẹlomiran ti o lee gba a. Emi ko bikita iye awọn alafarawe ti o wà ati awọn nkan miiran, o nilati wa nibẹ, nitori Ó mọ wipe iwọ yoo wà nibẹ. Bayi, a fi ọ han; bayi o lee ni idapọ pẹlu Rẹ, ohun ti Ó fẹ niyẹn. O n fẹ idapọ, wipe ki a sin Oun. Sugbọn ti ìgbé aye rẹ kò bá … ko ba ti sí tẹlẹ, gẹgẹbi èrò ninu Ọlọrun, o kan jẹ afarawe Kristẹni ni. Se ẹ rii? Ọpọlọpọ ọ̀kẹ́ aimoye wọn ni yoo wà ti yoo jẹ afarawe Kristẹni.

50 Ọrọ kan ti mo sọ laipẹ yii. Mo n sakiyesi Arakunrin Demos Shakarian nibẹyẹn nigbati wọn n ni … se ẹ̀dà maaluu, mo kiyesi igo ayẹwo ati awọn nkan bẹẹ, ti awọn dokita n ko wọle, ti wọn si n wo awọn nkan wọnyi.

Ninu iru (àtọ̀) ti akọ dà jade ninu ara, iru bii miliọnu kan ni o n jade lati ara akọ lẹẹkansoso. Bẹẹ naa ni bii miliọnu ẹyin ni o n jade lati ara abo lẹẹkannaa. Sugbọn njẹ ẹ mọ wipe ninu gbogbo awọn iru ti o n rin kaakiri yii, awọn ti o jẹ miliọnu kan, ẹyọkan ninu wọn ni a yan tẹlẹ si ìyè, ati wipe ẹyin kansoso ni o ni ìyè? Irú kekere yẹn yoo si fà kọja gbogbo awọn irú ti o kù, yoo gba ori gbogbo awọn irú ti o kù ti o dabii rẹ kọja, yoo si gba ori iyẹn kọja, yoo si wa sihin yii, yoo si ri ẹyin ti o ni ìyè ninu yẹn, yoo si fà wọ inu rẹ̀. Lẹyinnaa, gbogbo awọn ti o sẹku yoo ku. Eese, ti ẹ ba n sọrọ nipa iloyun wundia, kódà, kò tilẹ jẹ́ ijinlẹ ni ilaji, ti a ba fi we ìbí ti ara, bi a se yan-an tẹlẹ, ti Ọlọrun yan-an tẹlẹ.

Bayi, ni atetekọse, lẹyin lọhun, ni ọpọlọpọ ọdun ki àkókò to bẹrẹ, iwọ, ti o bá jẹ Kristẹni ti a ti tun bi ni asalẹ yii, o wà ninu Ọlọrun Baba rẹ nigba yẹn. Idi si niyẹn nigbati o wá si aye yii ti o si jẹwọ pe o jẹ Kristẹni, ohun gbogbo n sẹwọ odi, ó wá n ya ọ lẹnu, idi ti nkan yii fi ri bẹẹ. O n yà ọ lẹnu. Sugbọn lọjọ kan kini kan kọ lu ọ. Kini nkan naa? Ìyè ti o ti wà nibẹyẹn lati ibẹrẹ.

51 Gẹgẹbi itan kekere kan nipa ẹyẹ idi ti o n wa … iya rẹ̀ ti o n wa idi naa. Ẹ ti gbọ mi ti mo waasu lori iyẹn, bi a se pa ẹyin idi yẹn labẹ adiyẹ. Sugbọn ise rẹ lati fun awọn ọmọ adiyẹ yẹn naa ni ounjẹ, idì kekere yẹn ko lee jẹ ẹ́, nitori ki i se adiyẹ lati ilẹ wa, sibẹ ó wà ninu ọgba pẹlu awọn ọmọ adiyẹ, ó sì n tẹle awọn ọmọ adiyẹ naa. Sugbọn yoo fi ẹsẹ̀ tan ilẹ̀ ninu ọgba ati awọn nkan miiran, sugbọn idì kekere yẹn ko lee farada a. Sugbọn ni gbogbo igba ti àgbẹ́bẹ̀ adiyẹ yii ba kọ si awọn ọmọ rẹ, awọn ọmọ adiyẹ yii yoo lọ, idì naa yoo si lọ pẹlu.

Sugbọn ni ọjọ kan, iya rẹ mọ wipe ẹyin meji ni oun yé, ki i se ẹyọkan. Ọkan tun nilati wa nibikan. Ó lọ, o n wa a kiri. O n fò yipo kaakiri, nikẹyin o de ibi ọgba naa, o si ri ọmọ rẹ̀. O si kigbe pe e. O jẹ ohun ti o mọ wipe o ba ohun ti oun n fẹ mu. Ohun ti o ti n wá niyẹn. Se ẹ rii? Nigbanaa o mọ̀ wipe oun ki i se adiyẹ; idi ni oun. Bi o si se ri pẹlu gbogbo Kristẹni ti a ti tun bi niyẹn. Nigbati o bá wá, emi kò bikita oye ijọ ẹlẹkọ adamọ ti o ti darapọ mọ, oye igba ti o ti fi orukọ rẹ silẹ ninu iwe ati awọn nkan bẹẹ, nigbati a ba fi Ọrọ Ọlọrun tootọ han niwaju rẹ wipe ó jẹ otitọ, bẹyẹn, iwọ yoo mọ nibẹ wipe idì ni ọ. Nitori gbogbo didun adiyẹ yii, iwọ darapọ mọ eleyi, ki o tun darapọ mọ eleyi, ki o lọ si ọna yi ati ọna yẹn pẹlu, isọkusọ ni. Sugbọn ó jẹ ojulowo fifi ọrọ kun ọrọ.

52 Nigbati iru ba wá si inu ile ọmọ abo, ki yoo mu…. O kò lee jẹ iru eniyan lati inu baba rẹ, lẹyinnaa, ki o tun wa di iru aja, lẹyinnaa ki o tun di ologbo, lẹyinna ki o tun di adiyẹ; iru eniyan ni gbogbo rẹ. Ara Jesu Kristi pẹlu, iyawo naa, yoo jẹ apakan ara Rẹ, ti yoo…. Oun ni Ọrọ naa, iyawo si nilati jẹ Ọrọ naa, Ọrọ ti a fi kun Ọrọ, ti a fi kun Ọrọ. Idalare ti Luther, isọdimimọ ti Wesley, baptisimu Ẹmi Mimọ ti awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ, imubọsipo awọn ẹbun, ati gbogbo awọn ti o ku n ba a rin. Ó nilati jẹ ọrọ lori ọrọ, iru lori iru, ìyè lori ìyè, lati mu ẹkunrẹrẹ idagbasoke iyawo Jesu Kristi Oluwa jade.

Bayi, ẹ ranti, o jẹ èrò.

53 Bayi ohun ti o wa nibẹ ni wipe, lẹyin ti a ti se awari awọn nkan wọnyi, wipe Kristi n bọ wa fun iyawo Rẹ, bawo ni a se le wọ inu iyawo naa bayi? Ibeere naa niyẹn bayi. Ọpọlọpọ lo n sọ wipe, "Darapọ mọ ijọ wa." Ọkan ninu wọn n fẹ iru baptisimu kan. Ọkan fẹ se eleyi tabi iyẹn. Ọkan sọ wipe o nilati fede fọ̀, aijẹbẹẹ o koi tii ni I; omiran sọ wipe o kò nilati fede fọ. Eleyi sọ wipe o nilati jo ninu Ẹmi. Eleyi tun sọ wipe o nilati pariwo. Eleyi ni ẹ̀gbọ̀nrìrì ara. Gbogbo rẹ lo dara, sibẹ gbogbo rẹ lo kuna. Bawo ni ọkunrin kan ti o … tabi obinrin kan, tabi ọmọ Ọlọrun ti a bi nipa Ẹmi Ọlọrun, se lè sẹ́ Ọrọ Ọlọrun, nigbati Ọlọrun funra Rẹ tumọ rẹ ti O si wipe, "Oun niyi. Mo se ileri rẹ; oun niyi," ti O si n fihan ni gbangba kedere. Ẹ woo, dandan ni ki wọn ri I. Se ẹ rii? Bawo ni Kristi se le sẹ́ Ọrọ Oun funra Rẹ. Ti Kristi ba wa ninu rẹ, ko lee sẹ́ Ọrọ ara Rẹ.

54 Bawo ni a wa se lè wọ inu ara yii? I Korinti 12, "Nipa Ẹmi kan ni a baptisi gbogbo wa sinu ara kan," nipa baptisimu Ẹmi Mimọ kan. Ti ẹ ba fẹ kọ iyẹn silẹ, o wà ni I Korinti 12:13: "Ati nipa Ẹmi kan ni a baptisi gbogbo wa…." Ẹmi si ni iye Kristi (se bẹẹ ni?), ìyè Kristi. Bẹẹ si ni ìyè olukuluku iru - ti o si jẹ wipe Oun ni iru Ọrọ - maa n mu ki iru naa wa laaye. Se o ye yin? Ti iye yẹn ba wà ninu iru ti baptisimu Ẹmi Mimọ yi si bà le e, dandan ni ki o sọ iru yẹn di aaye.

55 Gẹgẹbi mo se sọ fun yin ni Phoenix, laipẹ yii mo n ba Arakunrin John Sharrit sọrọ. Mo si wà ni ita nibẹ, o si fi igi kan han mi, igi ọsàn. O gbin ọpọlọpọ igi ọsàn. O si fi igi kan han mi ti o ni orisi èso bii mẹjọ tabi mẹsan ni ori rẹ. Mo si sọ pe, "Arakunrin Sharrit, iru igi wo niyẹn?"

O ni, "Igi ọsan ni."

Mo ni, "Eese ti o fi ni ọsan wẹwẹ, tanjariini, tanjẹlo, ati ajara lori?

O ni, "Ọmọ iya ọsan ni gbogbo rẹ, a lọ́ wọn sinu rẹ ni."

Mo sọ pe, "O ye mi wayi. Bayi, ni ọdun ti o n bọ, eso ọsan nikan ni gbogbo rẹ yoo so."

Sugbọn o ni, "Ah, bẹẹkọ. Igi kọọkan yoo so tirẹ … ẹka kọọkan yoo so eso tirẹ."

56 Ọpọlọpọ ẹyin ti o n gbin igi eleso ni agbegbe igi ọsan nibi mọ iyẹn, wipe yoo so eso tirẹ.

Iwọ fi ẹka ọsan wẹwẹ si ara ọsan gidi, yoo so ọsan wẹwẹ, nitori o jẹ isẹda eso ọsan. Sibẹ ko nii so ojulowo eso. Ohun ti a si ti se niyẹn. A ti se àlọ́mọ́, àlọ́mọ́ pẹlu ẹkọ adamọ ati bẹẹ bẹẹ lọ, a si ti lọ́ olukuluku sinu rẹ nihin. Bawo ni ijọ Mẹtọdisti se le mu ohun miiran jade yatọ si ọmọ Mẹtọdisti? Bawo ni ijọ ẹlẹkọ adamọ se lè mu ohun miiran jade yatọ si ọmọ ijọ ẹlẹkọ adamọ?

Sugbọn ti igi yẹn ba tun yọ ojulowo ẹka tirẹ miiran, yoo mu eso ọsan gidi jade. Nitorinaa, ti Ọlọrun ba tun pada se ohun kan ninu ijọ, yoo pada jẹ́ ojulowo pẹlu Ọrọ naa lẹẹkan sii. Ó nilati ri bẹẹ, nitori inu igi naa ni ìyè wà, ó si n so iru ara rẹ̀.

57 Bayi, nigbati a rii…. Bayi, ijọ nla yẹn ti la gbogbo iran kọja, o si n so èso rẹ, bi ẹka rẹ si se n yọ ni wọn n

ge wọn kuro. Ninu Johannu Mimo 15…. Ko ge igi ọsan naa lulẹ bayi, o kan ge awọn ẹka yẹn kuro ni, o ge wọn kuro, nitori wọn kò máa so èso kankan. Awa si….

Jesu n fẹ èso fun ara Rẹ. Iyawo Rẹ gbọdọ bi iru ọmọ ti Oun jẹ. Njẹ ti wọn kò bá bi ọmọ, ọmọ iyawo, ọmọ Ọrọ, nigbanaa a jẹ wipe ọmọ ijọ ẹlẹkọ adamọ ni. Nigbanaa ifẹ rẹ àkọ́kọ́ ti o ni fun aye ati ijọ ẹlẹkọ adamọ, o ti pada sinu iyẹn. Wọn kò si lee bi ojulowo Kristẹni ti a ti tun bi, nitori ko si ohun ti wọn fi lee bi i nibẹ.

O dabi igba ti o mu ẹka ọsan wẹwẹ ti o lọ ọ mọ ibẹ; yoo mu èso ọsan wẹwẹ jade, sugbọn ko lee mu èso ọsan gidi jade, nitori kò si nibẹ lati ibẹrẹ. Sugbọn a ti yan-an tẹlẹ lati ibẹrẹ, imọtẹlẹ Ọlọrun ti yan-an tẹlẹ, o si bi i, o nilati mu ọsan gidi jade; ko lee mu nkan miiran jade.

58 Bi o se ri pẹlu ijọ Ọlọrun alaaye niyẹn. Nigbati wakati naa ba de, olukuluku…. Iwọ jẹ ki Ọlọrun bẹrẹ lati se nkankan, gbogbo awọn to kù ni yoo maa se iru nkankan naa. Se ẹ rii? Bi o se n ri nigbagbogbo niyẹn. Mo n ka itan Martin Luther nihin laipẹ yii. O sọ pe kò nira pupọ lati gbagbọ wipe Martin Luther lee tako ijọ Katoliiki ki o si mú u jẹ; o ni ohun ti o se ajeji nibẹ ni wipe, o lee duro gbọingbọin lai wo ti awọn gba-wèrè-m'ẹ́sìn ti o tẹle isọji rẹ, sibẹ o duro lori idalare. Se ẹ rii? Ohun gbogbo, afarawe ati ohun gbogbo lo tẹle e.

59 Ẹ wo Iyaafin Semple McPherson, Aimee Semple McPherson, ti o ni tẹmpili yii nibi yii. Gbogbo awọn obinrin oniwaasu ni o ni awọn ìyẹ́ naa ti wọn si n gbe Bibeli wọn ni ọna kannaa, afarawe ti ara lasan. Wọn ko lee jẹ́ ojulowo. Bi awọn ijọ se dà niyẹn. Iwọ jẹ́ ki ijọ kan ni nkankan tabi omiran laarin ilu, ara awọn ijọ ti o kù kò ní balẹ̀ ayafi igba ti awọn naa ba ni i. Se ẹ rii? Wọn kii se ojulowo mọ. Ọrọ Ọlọrun ni ojulowo. Ọrọ naa ni, Ó si nilati bi iru Rẹ̀ ni àkókò Rẹ̀, ayanfẹ, tí Ọlọrun Baba ti yan tẹlẹ.

Bayi, bawo ni a se n wọ inu ijọ yii? Nipa Ẹmi kan ni a baptisi gbogbo wa sinu ara kan yii, ara Kristi tii se iyawo, Ọrọ naa. A baptisi wa sinu rẹ nipa Ẹmi Mimọ.

60 Bayi, ẹ jẹ ki a wò ó boya a wà ni ìran ti o gbẹyin tabi bẹẹkọ. Bayi, a rii wipe ti a ba pada si Gẹnẹsisi, ni nkan bii, ah, nkan bii ori karun - ẹ tun lee si Luku naa - ki ẹ si rii wipe Enoku jẹ́ ẹni keje lati ọdọ Noah. Enoku…. Ibi ti a ti ri iru ẹranko-to-pada-di-ejo niyẹn, nitori ti Kaini ba jẹ ọmọ Abẹli, a jẹ wipe oun ni ẹni kẹjo. Se ẹ rii? Sugbọn kò si ibi kankan ninu Bibeli ti o sọ wipe Kaini jẹ ọmọ Abẹli … abi, Kaini jẹ ọmọ Adamu, nitori Bibeli sọ wipe ó jẹ ti ẹni buburu nni. Adamu kii sii se ẹni buburu nni. Se ẹ rii? O jẹ ti ẹni buburu nni.

61 Bayi, a rii nibi yii wipe Enoku jẹ ẹni keje lati ọdọ Noah, eyiti se apẹẹrẹ awọn igba ijọ. Bayi, gbogbo awọn mẹfa ti o saaju rẹ̀ kú, sugbọn a si Enoku nipo pada, a gba Enoku soke, ẹni keje, eyi n fihan wipe igba ijọ keje ni yoo lọ ninu igbasoke. Bayi, ko si iyemeji wipe a ti wà ninu igba ijọ keje. Gbogbo wa la mọ̀ ọ́.

Bayi, igba ijọ keje ni o lọ ninu igbasoke. Awọn mẹfẹẹfa ti o kù ni ó kú. Sugbọn a si Enoku nipo pada nitori a ko ri i; Ọlọrun mu u lọ. Sugbọn Enoku ti a gbà soke jẹ apẹẹrẹ gbogbo awọn ti o kù ti o n kú, sugbọn iyawo igba ikẹyin ni a o pè jade kuro ninu (igbasoke, laisi iku) ni a o pè jade kuro ninu igba ijọ keje. Eyiti a si n jẹri nipa ti igba yẹn bayi. Ah! Ẹ jẹ ki a gbẹ́ ẹ jinlẹ daadaaa bayi. Se ẹ rii?

62 Bayi, nihin ni a tun ri apẹẹrẹ igba ijọ meje, eyiti o wà ninu Ifihan 10:7, wipe ijinlẹ nla ti iwe naa ni a o sipaya nipa isẹ-ohun-Ọlọrun ti angẹli keje.

Bayi, ojisẹ kan wa loke gbogbo awọn wọnyi, ati ojisẹ kan lori ilẹ aye. Ọrọ ede oyinbo ti o sọ pe angẹli tumọ si "iransẹ." Ati ninu isẹ-ohun-Ọlọrun ti angẹli keje, nigbati o n fi tirẹ … polongo isẹ-iriju iwaasu rẹ, nigbati o ba n sọ isẹ iriju iwaasu rẹ jade, ki i se nigbati o kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀… Nigbati Jesu kọkọ bẹrẹ, O bẹrẹ pẹlu mímú alaisan ati awọn ti a n daloro lara da. "Ah! Rabbi nla nni, Wolii nla ni!" Olukuluku ni o si n fẹ Ẹ ninu ijọ rẹ, sugbọn nigbati O joko lọjọ kan ti o wipe, "Emi ati Baba Mi, ọkan ni wa," iyẹn wa yatọ. Iyẹn yatọ. "Ati wipe, biko se pe ẹ jẹ ẹran ara Ọmọ Eniyan ki ẹ si mu ẹjẹ Rẹ̀, ẹ ko ni iye ninu yin." "Eese, mujẹmujẹ ni." Se ẹ rii? Iyẹn yatọ. Kò Se alaye rẹ. Wọn ti ri ifarahan rẹ na, ifihan Ọrọ Ọlọrun fun iran Rẹ, ti a fihan daju ti a si fidi rẹ mulẹ fun wọn, wipe Oun ni ojisẹ fun iran yẹn. Kò si nílò lati se alaye ohunkohun.

Awọn ọmọ ẹyin yẹn kò ni lee se alaye rẹ, sugbọn wọn gba a gbọ, boya wọn le se alaye rẹ tabi bẹẹkọ. Wọn saa joko wọn si gba a gbọ. Bawo ni wọn se fẹẹ mọ boya wọn yoo jẹ ẹran ara Rẹ tabi mu ẹjẹ Rẹ? Eese, ko see se fun wọn lati se e, sugbon wọn gba a gbọ, nitori a ti yan wọn tẹlẹ. Jesu sọ wipe Oun ti yan wọn saaju ipilẹsẹ aye. Se ẹ rii? Wọn gba a gbọ. Boya wọn le se alaye rẹ tabi bẹẹkọ, wọn saa gba a gbọ.

63 Ẹ kiyesii bayi! Bayi, ni igba ijọ keje, nigbati angẹli keje yoo bẹrẹ sii dun, awọn ijinlẹ Ọlọrun ni a o sọ di mímọ̀ nibẹ. Awọn edidi ti awọn alatunse…. Ibasepe wọn ni àkókò ni…. Luther ko pẹ to laye, bẹẹ naa ni Wesley, awọn iran yẹn ko gbe pẹ to. Awọn alatunse yẹn, wọn ni isẹ-ohun-Ọlọrun fun ọjọ yẹn, awọn eniyan si mu u, wọn sọ ọ di ijọ ẹlẹkọ adamọ. Ki si ni?

64 Ẹ ko lee yan isẹda jẹ. Isẹda maa n jẹri nigbagbogbo. Ọlọrun maa n tẹsiwaju pẹlu isẹda. O nilati ri bẹẹ.

Bii oorun, oorun yoo yọ ni owurọ; o jẹ́ ọmọ-ọwọ ti a sẹsẹ bi. O se alailera, ko iti ni ooru pupọ. Ni agogo mẹwa, o n jade ile-iwe giga. Ni ọjọkanri, ó bọ́ saye. Ni agogo mẹta ọsan, o ti ndàgbà. Ni agogo marun, o ti n ku lọ, o ti darugbo, o si ti di alailagbara, o n pada lọ si iboji. Se opin rẹ niyẹn? Yoo tun yọ ni owurọ ọjọ keji. Se ẹ rii?

Ẹ wo bi awọn igi se n yọ ewe wọn, ati ohun gbogbo ti wọn n se. Bayi, a rii wipe awọn ewe n jabọ kuro lara igi, wọn pada. Kini? Ìyè wọn pada sọkalẹ sinu gbongbo igi naa. Se opin rẹ niyẹn? Yoo tun pada wa ni igba òjò pẹlu ìyè titun.

65 Bayi, ẹ wo awọn ijọ, bi wọn se se nkan kannaa ninu atunse. O hù jade. Horo ọka yẹn subu sinu ilẹ, o si kú labẹ inunibini igba Okun Biribiri. O wọ inu ilẹ lọ. O nilati ku. Ẹnikẹni ti o ba jẹ ẹni ẹmi lee ri iyẹn. Bikosepe irugbin yẹn ba kú ki o si rà, yoo dánìkan wà ni. Ó si nilati wọ inu ilẹ lọ ni igba Okunkun Biribiri. O duro sibẹ, o rà, o si yọ jade pẹlu èéhù ewe meji ti ijọ Luther. Lati inu ijọ Luther ni o ti mu awọn ewe miiran jade wa, Zwingli ati bẹẹ bẹẹ lọ. Lati inu iyẹn ni o ti dagba soke wa si irukẹrẹ, eyiti i se John Wesley, àkókò nla ti awọn akiri-waasu. O tun pada sẹyin. Lati inu iyẹn ni iran itanjẹ yẹn ti jade wa, iran awọn Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. Horo alikama yẹn, ti….

Njẹ a ri ẹnikẹni níbí ti o gbin alikama ri? Ẹyin ẹ wo alikama yẹn. Nigbati ẹ ba wo o…. Nigbati ẹ ba jade lọ sibẹyẹn ti ẹ sọ pe "Mo ti ni alikama." O dabi ẹni wipe ẹ ni alikama nibẹyẹn, ẹ si i daradara ki ẹ si wò ó fín, ẹ o ri i wipe ẹ kò ni alikama kankan rara. Eepo ni ẹ ni. Njẹ Jesu kò ha kìlọ̀ iyẹn fun wa ni Mattew 24:24, pe ni ikẹyin ọjọ, awọn ẹmi mejeeji yoo jọ ara wọn tobẹẹ gẹẹ ti yoo tan ayanfẹ alikama funra Rẹ jẹ ti o ba see se. Se ẹ rii? Ẹ kiyesii bayi, alabaru lasan ni.

66 Bayi, ìyè ti o jade lati inu Luther naa ni o di Wesley. Ìyè ti o jade lati inu Wesley naa ni o di ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. Ìyè ti o jade lati inu ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ni o di alikama. Sugbọn wọn jẹ alábárù. Se ẹ rii? Iye tootọ gba ibẹ kọja. Isẹ-ohun-Ọlọrun naa gba ibẹ kọja, sugbọn gbogbo rẹ n pari si alikama. Idi niyẹn ti alikama fi jade wa ti o si mu gbogbo rẹ wa ninu igbasoke ni oke. Iyawo funra rẹ n jade lati inu iran kọọkan, sugbọn awọn pòpórò ijọ ẹlẹkọ adamọ kú, o gbẹ, o si kú.

Njẹ ẹ ti kiyesi awọn ikẹyin ọjọ wọnyi, bi o se n si kuro bayi? Nigbati alikama yẹn bẹrẹ sii dagba, nigbanaa awọn eepo bẹrẹ lati si kuro lara rẹ.

67 Ẹ pada wo alikama kekere yẹn, nigbati ẹ ba wò ó. Ẹ si i ki ẹ si wo inu rẹ; ẹ o ri idi alikama kekere kan nibẹ. Ẹ nilati lo ẹ̀rọ amú-nkan-gbòòrò ti o lagbara lati wò ó ki ẹ to lee ri idi alikama ti o wa nibẹ. Se ẹ rii? O wà ninu ibẹyẹn, sugbọn yoo bẹrẹ si dagba. Bayi, eepo yẹn nilati wa nibẹ lati daabo bo o, ki o lee fun-un ni aaye lati jade. Sugbọn nigbati o ba n dagba ti isẹ-ohun-Ọlọrun naa bẹrẹ si gbilẹ̀, nigbanaa eepo naa yoo sí kuro lara rẹ̀. Ìyè yoo si jade kuro ninu eepo yẹn lọ sinu alikama. O ntẹsiwaju. Bi iran kọọkan se maa n se niyẹn. Ko saa lee yan isẹda jẹ; itẹsiwaju Ọlọrun niyẹn, bi Oun se maa n se nkan.

68 Ni bayi, ìran ti a n gbé ninu rẹ niyẹn lọwọlọwọ bayi, igba ijọ keje.

Bayi, gbogbo rẹ nilati farahan ninu hóró ọka ni opin. Ipadawa miiran…. Bayi, ti ẹ ba mu Luku ori 17, ẹsẹ 30, O sọ pe, "Gẹgẹbi o se ri ni ọjọ Sodomu, bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ Eniyan yoo wa, nigbati Ọmọ Eniyan ba n fi ara Rẹ han." Kini fifihan? Sise ifihan ohun ti Oun jẹ ni ọjọ oni, fihan fun awọn eniyan, Ọrọ naa ti a sọ di mimọ fun ọjọ oni, ti a fihan fun awọn eniyan nipa ifarahan Ẹmi Mimọ, eyiti o n mu Jesu wa laaye laarin wa.

Ẹ si ranti, O farahan nibẹyẹn ninu ọkunrin kan - ọkunrin kan. O sọ pe, "Bi o se ri." Bayi, O ka Bibeli kannaa ti a ka, Gẹnẹsisi. Bayi, a kiyesii ni ori Gẹnẹsisi yẹn nigbati Jesu n sọrọ nipa rẹ.

69 A rii nibẹ wipe o kọ ẹ̀yìn si àgọ́, Sarah si wà ninu àgọ́, O sọ pe - O beere ibeere kan. Oun ko si gbagbọ wipe ohun ti yoo sẹlẹ lee sẹlẹ. O sọ pe, "Bayi, Abrahamu, Emi yoo bẹ ọ wò gẹgẹbi àkókò ìyè." Sarah ti o wa ninu àgọ́ si rẹrin nipa rẹ. O ni, "Eese ti Sarah fi rẹrin ninu agọ, ti o nwipe, 'Bawo ni awọn nkan wọnyi se lee ri bẹẹ?'" Jesu se ileri, Oun si niyẹn;, Abrahamu pe E ni Ẹlohimu, Olodumare. Oun niyẹn.

Bayi, Bibeli sọtẹlẹ wipe yoo tun pada lẹẹkan sii ni awọn ikẹyin ọjọ wọnyi. Jesu sọ bẹẹ. Nigbati ẹ ba si ri awọn nkan wọnyi ti wọn n wa si imusẹ, ẹ saa ranti, nigbati nkan yii ba n sẹlẹ bẹyẹn, nigbanaa ki ẹ mọ wipe akoko ti sunmọ tosi.

70 Ẹ wo aye funra rẹ. Ẹ wo aye, Sodomu ni, ti Sodomu kan ba wa. Ẹ wo awọn eniyan, wọn ti dibajẹ ninu ibajẹ wọn. Ọkàn wọn ti dibajẹ. Wọn kò mọ ohun ti iwa ọmọluwabi jẹ. Ẹ wo awọn ti kò tẹle ofin, awọn ti n fi ọkunrin ba ara wọn jẹ, ati ohun gbogbo ti o kù. Ẹ wo awọn obinrin wa, iru ibajẹ wọn ti o gbilẹ. Ẹ wo iwa aimọ ti o gbilẹ, isekuse laarin awọn obinrin wa, kii si se awọn tiwa nikan…. O sọ pe, "Ijọ Eleto niyẹn." Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ pẹlu. Gbogbo rẹ ni.

Ẹ wo awọn ọkunrin wa; wọn rọ̀ mọ́…. Dipo Ọrọ Ọlọrun, awọn àsà ijọ ẹlẹkọ adamọ kan ti wọn rọ mọ,

dipo ki wọn jade nigbati wọn ri Ọlọrun ti o n fi ara Rẹ han ni pipe. Idi ni wipe, wọn fọju, wọn ko lee ri i. Wọn ko si lee ri i laelae.

Bayi ẹ kiyesi ohun ti o sẹlẹ nihin ninu eleyi, bi a o se yara. Mo lero wipe obinrin yẹn n fẹ ki a kuro; mo ri i ti o n ju ọwọ rẹ, o n se ami wipe oun fẹ ki a kuro, nitorinaa a gbọdọ yara.

71 Bayi, ẹ kiyesi Enoku, apẹẹrẹ ijọ. A tun fi oun naa we igba ijọ meje pẹlu. Njẹ ẹ le ronu nipa iyẹn? Igba ijọ meje…. Kiyesii, ni igba didun ti ….

Ẹni melo lo gbagbọ wipe awọn iransẹ meje ti wa fun igba ijọ meje…? Ah, gbogbo wa la gba iyen gbọ, ti a ba gba Bibeli gbọ. Ti a ko ba gba Bibeli gbọ, nigbanaa (se ẹ rii) a ko gba a gbọ. Sugbọn o ti wa…

Bayi, a ngbe ni igba ijọ keje. Nigbati Bibeli si sọ wipe igba ijọ keje yii… Nigbati ojisẹ igba ijọ keje yii ba bẹrẹ si mu isẹ-ohun-Ọlọrun wa, wipe ijinlẹ gbogbo awọn nkan ti wọn ti lọ́ lọrun ni gbogbo awọn iran ni a o fihan ni akọkọ yẹn. A si ti rii bayi, Ọmọ Eniyan wa si aarin awọn eniyan Rẹ, O si n se ohun kannaa, o n fi idi isẹ-iransẹ iwaasu Rẹ mulẹ bi o se so wipe Oun yoo se. A ti rii bayi ni iran ti o kẹyin yii.

Bayi…. Ati awọn ìsọ́ meje, bi awọn igba ìsọ́ meje. Kò wá ni ìsọ́ akọkọ, ekeji, ẹkẹta, ẹkẹrin, sugbọn O wa ni ìsọ́ keje. Iyẹn ni Enoku, ikeje, ti a gba soke, ati Noah, ti o jẹ apẹẹrẹ awọn Juu ti o kụ, ni a o gbe rekọja.

Bayi, ni igba Bibeli - a n sọrọ nipa awọn ìsọ́ - a ko pin awọn òru si wakati ni igba Bibeli.

72 (Ẹ feti silẹ daradara bayi, nitori n o yara bayi, nitori wọn n fe lo yara yii.) Rara, a ko pin Bibeli … tabi, a ko pin òru si awọn wakati ni igba Bibeli; a pin wọn si ìsọ́ ni.

Ìsọ́ mẹta lo wa. Bayi, ìsọ́ akọkọ bẹrẹ lati agogo mẹsan titi di mejila; ìsọ keji bẹrẹ lati agogo mejila titi di agogo mẹta, isọ kẹta òru si bẹrẹ lati agogo mẹta si agogo mẹfa. Bayi, a ni ẹẹta lọna mẹta, ti o jẹ mẹsan, nọmba ti ko pe perepere. Nigbanaa a o pada wa si meje fun igbasoke, ti mo gbagbọ wipe yoo sẹlẹ laarin agogo mẹfa si meje … tabi agogo mẹfa si mẹsan lowurọ ọjọ kan. Nitori ipe Oluwa yoo dun…

Lowurọ ọjọ ajinde

Nigbati ipe yoo dun

A o pin ninu ogo ajinde;

Gbati awọn ayanfẹ

yoo pejọ ni oke orun,

Gba ta ba nporukọ lọhun

n o wa n bẹ.

73 Ọrọ ti a n pe ni “igbasoke” ninu Bibeli, a kò tilẹ lo o rara. Awa la kan fi ọrọ yẹn sibẹ. Bibeli wipe, “Mu lọ soke, mimu lọ soke.” A ka a ni II Tẹssalonika tabi I Tẹssalonika ni, ètò ti igbasoke nla yii ti yoo sẹlẹ ni ikẹyin ọjọ. Ẹ feti si eleyi. A o bẹrẹ lati ẹsẹ kẹtalạ.

…N ko fẹ ki ẹ … ope, ara, niti awọn ti o sun, pe ki ẹ mase banujẹ, ani bi awọn to kù ti kò ni ireti.

Nitori ti awa ba gbagbọ … Kristi kú o si tun jinde, bẹẹ ni awọn … ti o sun ninu Jesu ni Ọlọrun yoo mu wa pẹlu Rẹ̀.

Nitori … eyi ni a sọ fun yin nipa Ọrọ Oluwa, wipe awa ti o wa laaye ti ó sì sẹ́kù de atiwa Oluwa, ki yoo saaju [ọrọ saaju yii tumọ si “lati di lọwọ.”] awọn ti o sun.

Nitori Oluwa funra Rẹ yoo sọkalẹ [Bayi, ẹ feti silẹ daradara.] … Oluwa funra Rẹ yoo sọkale lati ọrun wa pẹlu ariwo, ati pẹlu ohun olori awọn angẹli, ati … ipe Ọlọrun: awọn oku ninu Kristi ni yoo si kọ jinde:

74 Bayi, mo fẹ ki ẹ kiyesi ohun nla kan ti o sẹlẹ nibi yi bayi. Ẹ mase padanu eleyi. Se ẹ rii? Ẹ kiyesii bayi, Ọrọ naa sọ nihin ni II Tẹssalonika wipe awọn nkan mẹta ni o wà…. Kiyesi, lati ẹsẹ 13 titi de 16, awọn nkan mẹta ni o nilati sẹlẹ ki Oluwa funra Rẹ to farahan. (Ni kiakia bayi, ki a le pari. Se ẹ rii?) Ohun akọkọ ti yoo sẹlẹ, ẹ kiyesii: ariwo, ohun, ipe. Ẹ jẹ ki a ka a bayi ki a si wo o boya o ri bẹẹ. Se ẹ rii?

Nitori Oluwa funra Rẹ [ẹsẹ 16] yoo sọkalẹ lati ọrun wa pẹlu ariwo, ati pẹlu ohun olori awọn angẹli, ati … ipe Ọlọrun: …

75 Awọn nkan mẹta ni ó sẹlẹ; ohùn … ariwo, ohùn, ipè, nilati sẹlẹ ki Jesu to farahan. Bayi, ariwo. Jesu ni o

se mẹtẹẹta nigbati Ó ba n sọkalẹ. “Ariwo” kan, kini “ariwo”? Iyẹn ni isẹ-ohun-Ọlọrun ti o kọkọ jade lọ, ounjẹ iye ti o n mu iyawo jade wa.

Bayi, Ọlọrun ní ọna ti O maa n gba se nkan, kii sii yi ilana Rẹ pada. Ko yi nkan Rẹ pada ri…. Ọlọrun ti kii yipada ni. Ni Amosi 3:7 O sọ pe Oun ki yoo se ohunkohun lori ilẹ aye ayafi ti O ba kọkọ fi han fun awọn iransẹ Rẹ̀, awọn wolii. Bi o si se daju pe O se ileri Rẹ, yoo se e.

76 Bayi, a ti la awọn igba ijọ kọja, sugbọn a se ileri fun wa pe ni ikẹyin ọjọ, ni ibamu pẹlu Malaki 4, wipe wolii kan yoo tun pada wa si aye. Bẹẹni! Ẹ kiyesi iwa isẹda rẹ̀ ati ohun ti yoo jẹ. Ọlọrun lo ẹmi yẹn ni igba marun: akọkọ ninu Elijah, ninu Elisa, ati Johannu Onitẹbọmi, o pe ijọ jade, ati iyoku awọn Juu; igba marun, oore-ofẹ, J - e - s - u, i - g - b - a - g - b - ọ, o si jẹ nọmba oore-ofẹ. Se ẹ rii? O dara.

77 Ẹ ranti bayi, a se ileri isẹ-ohun-Ọlọrun naa. Nigbati awọn ijọ si ti da gbogbo awọn ijinlẹ wọnyi ru mo ara wọn loju lati ọwọ awọn oniwaasu, yoo gba wolii kan taara lati ọdọ Ọlọrun wa lati fi i han. Ohun ti O si se ileri lati se gan-an niyẹn. Se ẹ rii?

Ẹ ranti bayi, Ọrọ Oluwa maa n tọ wolii wa, ki i se ẹlẹkọ ẹsin, sugbọn wolii. O jẹ olufihan Ọrọ Ọlọrun. Ko lee sọ ohunkohun; ko lee sọ ero ti ara rẹ; kiki ohun ti Ọlọrun ba fihan nikan ni o lee sọ. Ti o fi kan wolii Balaamu paapaa, nigbati o gbiyanju lati ta ẹ̀tọ́ rẹ; o ni, “Bawo ni wolii kan se le sọ ohunkohun bikose ohun ti Ọlọrun fi si ẹnu rẹ̀? Ohun ti Ọlọrun n se ni, o kò si lee sọ ohun miiran. A bi ọ bẹẹ ni.

Ko ju pe ẹ lee….

78 Ti o ba le sọ pe, “N ko le la oju mi,” nigbati o si n wò. Se ẹ rii? O le se e. O ko lee maa nọ̀gà nigbati o lee riran. Se ẹ rii? O ko lee jẹ́ aja nigbati o jẹ́ eniyan. Se ẹ rii? A kan da ọ bẹẹ ni, Ọlọrun si nilati, nigbagbogbo … ni awọn iran nipasẹ Isaiah, Jeremiah, ati gbogbo … Elijah, ati awọn iran ti o ti kọja lọ, nigbati awọn ẹgbẹ oniwaasu ti da gbogbo nkan ru, Oun yoo ran wolii, yoo si gbée dide lati ibiti ẹnikẹni ko fojú si. Ko ni darapọ mọ ẹgbẹ wọn kankan, yoo si sọ Ọrọ Rẹ̀, a o si pee kuro loju agbo, awọn ẹni otitọ Ọlọrun ti o yigbi.

Ati nigbagbogbo o maa n jẹ…. Bi ẹ se lee mọ̀ ọ́, O sọ pe, Ti ẹnikan ba wà laarin yin ti o jẹ ẹni ẹmi tabi wolii….“

79 Bayi, wolii…. Nkankan wa ti a n pe ni ẹbun isọtẹlẹ ninu ijọ, sugbọn a maa n yan wolii tẹlẹ ni, a si maa n mọ̀ ọ́ tẹlẹ fun wakati yẹn. Se ẹ rii? Bẹẹni, sa.

Bayi, ti isọtẹlẹ ba jade lọ, ẹni meji tabi mẹta nilati joko ki wọn si yẹ̀ ẹ́ wò boya o tọnà tabi bẹẹkọ ki ijọ to lee gba a. Sugbọn kò si ẹnikan ti a gbe siwaju wolii, nitori oun ni Ọrọ Ọlọrun dajudaju. Oun ni Ọrọ yẹn ni ìgbà tirẹ. O rii ti Olorun n fi han….

Bayi, ti Ọlọrun ba ti se ileri lati fi iyẹn ransẹ si wa ni ikẹyin ọjọ, lati mu iyawo jade kuro ninu rẹ́dẹrẹ̀dẹ ẹ̀sìn, ọna kansoso ti a le gba se e.

80 Ko lee see sese laelae…. ijọ ko lee gba Kristi. Awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ, a ko lee mu ki isẹ-ohun-Ọlọrun yii tẹsiwaju ni ipo ti ijọ wa loni. Bawo ni a se fẹ mu igba ikẹyin jade ni ipo ti wọn wa loni, nigbati gbogbo wọn lodi si ara wọn, ati ohun gbogbo miiran, ninu isẹ́ ìsìn? Oluwa saanu. Rẹ́dẹrẹ̀dẹ ni. O ti di ijọ ẹlẹkọ adamọ. Ati nigbakuugba, mo beere lọwọ onkọ̀tàn yoowu lati sọ ti ko ba ri bẹẹ. Ni gbogbo igba ti isẹ-ohun Ọlọrun kan ba jade lọ lori ilẹ aye, ti wọn ba si ti fi ọgbọn eniyan gbee kalẹ, yoo kú sibẹ ni. Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ si ti se nkan kanna bi gbogbo wọn ti se - ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ti o jade.

81 Ẹyin ijọ Ipejọpọ ti Ọlọrun, nigbati awọn baba nla yin ati awọn iya yin jade kuro ninu awọn ijọ ti a fi ọgbọn eniyan gbẹ kalẹ nibi Igbimọ Gbogboogbò atijọ nni, ti wọn pariwo, ti wọn si yin Ọlọrun, ti wọn si sọrọ tako awọn nkan; ẹ si pada bii aja sinu èébì rẹ, ati bii ẹlẹdẹ sinu ẹrọ̀fọ̀ rẹ̀, ẹ si se nkan kannaa ti wọn se; ati ni bayi, ẹ kun fun ẹsin lasan debi wipe ẹ sé ọkàn aanu yin pa, ẹnikan si nilati ni iwe idapọ ki o to lee ni idapọ pẹlu yin.

Ati ẹyin ti o gbagbọ wipe ẹni kan ni o wa ninu ọlọrun, Ọlọrun fun yin ni isẹ-ohun-Ọlọrun bi iyẹn, dipo ki ẹ rẹ ara yin silẹ, ki ẹ si tẹsiwaju, nse ni ẹ sọ ẹgbẹ yin di ijọ ẹlẹkọ adamọ. Nibo ni gbogbo yin wa bayi? Ninu òsùnwọ̀n kannaa. Bẹẹ gan ni! Ẹmi Ọlọrun si ntẹsiwaju. “Emi Oluwa yoo gbin; Emi yoo si bomirin tọsan toru, ki ẹnikẹni ma baa…”

O yan awọn nkan wọnyi lati wa, O si nilati fi eyi ransẹ.

82 Ohun àkọ́kọ́ ti yoo sẹlẹ nigbati Ó ba nsọkalẹ lati ọrun wa ni wipe, ariwo kan yoo wà! Ki ni? Isẹ-ohun-Ọlọrun lati kó awọn eniyan jọ ni. Isẹ-ohun-Ọlọrun kan yoo kọ́kọ́ jade lọ na. Bayi, “Akoko lati tun atupa se. Ẹ dide ki ẹ tun atupa yin se.” Ìsọ́ wo niyẹn? Ikeje, kii se ikẹfa, ikeje ni. “Woo, ọkọ iyawo n bọ. Ẹ dide ki ẹ tun atupa yin se.” Wọn si se bẹẹ. Awọn kan ninu wọn si rii wipe awọn kò tilẹ ni ororo kankan ninu atupa wọn. Se ẹ rii? Sugbọn o jẹ àkókò lati tun atupa se. O jẹ akoko Malaki 4, ohun ti O… O jẹ Luku 17. O jẹ Isaiah…

Gbogbo awọn asọtẹlẹ yẹn ti o lee duro daradara ninu Iwe Mimọ loni, a rii ti o wa laaye nibẹyẹn. Ko si….

83 Se ẹ ri awọn nkan wọnyi ti o nsẹlẹ, arakunrin mi ọwọn, arabinrin, ti Ọlọrun ọrun si mọ̀ wipe mo lee ku ni ori pẹpẹ yii bayi, o kàn nilati rìn kaakiri fun igba diẹ. O kan jẹ… O lagbara, nigbati ẹ ri Ọlọrun sọkalẹ wa lati ọrun, ti O si duro niwaju awọn eniyan, ti O si duro sibẹ, ti O fi ara Rẹ han bi O se maa n se. Otitọ si niyẹn, pẹlu Bibeli yii ni sisi. Se ẹ rii? A ti wa nihin!

Ilana ijọ ẹlẹkọ adamọ ti kú. Ó ti lọ. Ko lee ji dide mọ laelae. A o fi ina sun-un. Ohun ti a maa n se si eepo ni oko niyẹn. Ẹ sa kuro ninu rẹ. Ẹ wọ inu Kristi. Mase sọ pe, "Mo je ọmọ ijọ Eleto!"; "Mo jẹ ọmọ ijọ Onitẹbọmi"; "Mo jẹ ọmọ ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ!" Iwọ wọ inu Kristi. Ti o ba si wà ninu Kristi, kò si ọrọ kan ti a kọ sihin ti o kò ni gbagbọ. N ko bikita ohun ti ẹnikẹni sọ. Ọlọrun yoo si jẹ ki nkan yẹn farahan, nitori o…. Nigbati o tu Ẹmi dà si ori Ọrọ, ki lo sẹlẹ? O dabi igba ti eniyan da omi sori irugbin kan ni. Yoo yè, yoo si mu eso iru ara rẹ jade.

84 O sọ pe, "Mo ni baptisimu Ẹmi Mimọ." Iyẹn ko sọ pe a ti gba ọ la, ko tilẹ jọọ́ rara.

Wo ibi, o jẹ ẹda alara mẹta. O jẹ…. Ninu ẹni kekere yii ni ọkàn wà; ekeji ni ẹ̀mí, ẹkẹta ni ara. Bayi, o ní awọn ònmọ̀ marun ninu ara yii lati le se pẹlu ilé rẹ ninu aye. Wọn kò ni nkankan se pẹlu awọn ti o kù. O ni ònmọ̀ marun ti ẹ̀mí naa nibi, ìfẹ́ ati ẹ̀rí ọkan ati bẹẹ bẹẹ lọ bẹyẹn. Sugbọn ninu ibi yii ni o n gbe. Ohun ti o jẹ niyẹn.

Se Jesu ko sọ wipe òjò n rọ sori olododo ati alaisododo. Fi èpò si ibẹyẹn, ati alikama si ibẹyẹn, ki o si da omi le wọn lori, ki o si fi wọn si ibi ajílẹ̀ ati awọn nkan bẹyẹn, njẹ awọn mejeeji ki yoo yè nipa omi kannaa bi? Dajudaju! O dara, ki ni? Ọ̀kan ninu wọn yoo so èpò, nitori gbogbo ohun ti ó jẹ niyẹn. Epo yoo gbe ọwọ rẹ̀ soke yoo si pariwo gẹgẹbi alikama naa se se.

85 Njẹ Bibeli ko ha sọ wipe ni ikẹyin ọjọ, awọn èké Kristi yoo wà, kii se awọn eke Jesu bayi, awọn eke Kristi ni, awọn ẹni-ami-ororo, ti a ta ami ororo eke si ni ti Ọrọ naa. Ami-ororo ijọ ẹlẹkọ adamọ, sugbọn kii se si Ọrọ naa, nitori Ọrọ naa yoo jẹri ara Rẹ. Kò nilo ohun miiran; yoo jẹri ara Rẹ. Awọn ẹni-ami-ororo eke yoo si wa. Ẹ nì ohùn-ti-a-gbasilẹ mi lori iyẹn. Iyẹn si ni ami-ororo…. Ah, ti o bá pe ọ̀kan ti o si wipe, "A, se Jesu kan ni ọ?", "Ah, dajudaju bẹẹkọ!" Wọn ko ni gba iyẹn. Sugbọn nigbati o ba di, "Ah, ogo, mo ni ami-ororo…." Ami-ororo tootọ si ni.

Ẹ ranti, Kaiafa naa ni i, o si sọtẹlẹ. Bẹẹ naa ni Balamu ni i, o si sọtẹlẹ, sugbọn iyẹn ko ni nkankan se pẹlu inu yii. Bikose wipe iyẹn bá jẹ́ iru Ọlọrun, iru Rẹ lati ibẹrẹ, ti a yan tẹlẹ, o ti tan niyẹn. N ko bikita bi o se pariwo to, bi o se fede fọ to, sare, pariwo; iyẹn ko ni nkankan se pẹlu rẹ̀. Èpò lee pariwo gẹgẹbi awọn to kù. Mo ti ri awọn keferi ti wọn dide, pariwo, fedefọ, ti wọn si n fi agbari eniyan mu ẹjẹ, ti wọn si n pe esu. Se ẹ rii? Nitorinaa, ẹ kò fẹ ọkankan ninu awọn ìjìlára ati awọn nkan yẹn; ẹ gbagbe rẹ. Ọkàn rẹ ninu Ọrọ yẹn ni, Kristi si niyẹn. Ẹ mu u wa sibẹ, ki ẹ si wo bi yoo se fi ara rẹ han, gẹgẹbi yoo se si ara rẹ̀ bi awọn iru miiran, ti yoo si sọ ara rẹ di mimọ fun iran ti o n gbe inu rẹ.

86 Luther ko lee mu ohun kan wa bikose isẹpẹ igi. Awọn ti o kù wọnyi lee mu awọn nkan ti o kù wá. A ti wà ni igba alikama bayi. Awọn atẹle Luther, ojulowo ọmọ ijọ Luther nilati bi ojulowo ọmọ ijọ Luther. Ojulowo ọmọ ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ nilati bi ojulowo ọmọ-ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. Ko ju bẹẹ lọ. Sugbọn a ti kọja àkókò yẹn bayi, a si n tẹsiwaju.

Njẹ ẹ mọ wipe ijọ Katoliiki bẹrẹ gẹgẹbi ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ? Ti ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ba si wà fun ẹgbàá ọdun, yoo bajẹ ju bi ijọ Katoliiki se ri bayi lọ. Otitọ niyẹn! Mo n sọ iyẹn fun awọn arakunrin mi ati awọn arabinrin mi ti mo fẹran, Ọlọrun si mọ iyẹn. Sugbọn ẹ ranti, ẹyin ọ̀rẹ́, mo nilati pade yin nibi idajọ. Iyẹn si lee ma pẹ mọ. Mo nilati jẹri si ohun ti i se otitọ.

87 Nigbati mo ba lọ si ibi ipade ti mo si ngbadura fun awọn alaisan, iyẹn dara, sugbọn nigbati mo ba wà pẹlu isẹ-ohun-Ọlọrun …. Ti isẹ-ohun-Ọlọrun kan ba jade lọ, ti o bá jẹ́ isẹ-ohun-Ọlọrun tootọ, ti o ba jẹ isẹ-iyanu Ọlọrun nitootọ, ti o ba si duro si aarin ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ, ẹ mọ wipe ki i se ti Ọlọrun, nitori a ti sọ nkan yẹn na. Jesu jade lọ mu awọn alaisan lara da ki O baa le fa oju awọn eniyan mọra, lẹyinnaa isẹ-iransẹ iwaasu Rẹ̀. Otito niyẹn! Nkankan nilati wà ti Ọlọrun yoo fi saaju. Iwosan lati ọrun wa jẹ … awọn isẹ-iyanu bẹyẹn kan maa n fa oju awọn eniyan mọra ni. Kókó ibẹ gan-an ni isẹ-ohun-Ọlọrun. Iyẹn ni. Ohun ti o ti inu ọkàn wá ni. O ngbiyanju lati ri ojurere awọn eniyan naa, ki wọn baa lee joko feti si I. Se ẹ rii? Nitori awọn kan wà nibẹ ti a ti yan tẹlẹ si ìyè. Diẹ ninu awọn alikama naa bọ silẹ, awọn ẹyẹ si sa a jẹ. Awọn kan bọ si aarin ẹgun, awọn kan bọ si ilẹ ti a ti pèsè, ilẹ ti a ti pèsè silẹ, o si so èso.

88 Bayi, ohun àkọ́kọ́ ni didun - tabi ohun àkọ́kọ́ ni ìpè tabi ohun kan - ariwo kan, lẹyinna ohùn, lẹyinna ìpè. Ariwo, òjísẹ́ kan ti o n pèsè awọn eniyan silẹ. Ikeji ni ohùn ajinde. Ohùn kanna, ohun rara ni Johannu Mimọ 11:38 ati 44 ti o pe Lasaru jade kuro ninu iboji. O n ko iyawo jọ papọ, lẹyinnaa ajinde awọn oku (se ẹ rii?), lati

ko wọn lọ soke pẹlu rẹ. Bayi, ẹ kiyesi awọn nkan mẹta ti o nsẹlẹ.

Kini ohun ti o kan? ìpè ni. Ohun kan - ariwo kan, ohùn kan, ìpè kan.

89 Bayi, ohun kẹta ni ipe, eyiti a maa n fi pe awọn eniyan sibi àsẹ̀ ipe; iyẹn si ni yoo jẹ àsè ti iyawo, ase Ọdọ-aguntan pẹlu iyawo ni oju ọrun.

Se ẹ rii, ohun akọkọ ti o jade wa ni isẹ-iransẹ iwaasu Rẹ̀ lati pe iyawo jọ papọ. Ohun ti o tẹle e ni ajinde awọn iyawo ti o sùn, awọn ti o kú ni awọn iran ti o ti kọja. A ko wọn papọ, ati ipe, ase ni ọrun - ni ofuurufu. Eese, ohun ti yoo sẹlẹ niyẹn, ẹyin ọ̀rẹ́.

A ti wà ninu rẹ̀ bayi. Ohun kan ni, ijọ ti o jade nilati wà niwaju òòrùn lati pọn. Ẹ̀rọ ikore nla naa yoo wa laipẹ. Alikama naa … a o fi ina sun poporo, sugbọn alikama ni a o ko sinu aka rẹ. Se ẹ rii?

90 Ẹ kii se afọju eniyan. Ọlọgbọn eniyan ni yin, ti mo ba si duro sibi ti mo sọ awọn nkan wọnni pẹlu èrò buburu lọkan…. Mo sọ ọ nitori o jẹ iye, nitori mo ni ojuse fun Ọlọrun lati sọ ọ. Mo si gbọdọ sọ ọ. Ati isẹ-iransẹ iwaasu mi…. Ti mo si ti mọ tẹlẹ ni àkókò sise iwosan ati bẹẹ bẹẹ lọ bẹyẹn, ni lati fa oju awọn eniyan mọra, ti mo mọ wipe iwaasu naa yoo wa. Oun si niyi.

Awọn edidi meje na si, awọn ijinlẹ wọnyẹn, o si n fihan wipe awọn nkan ti o sẹlẹ niyẹn. N ko mọ̀ ọ́ tẹlẹ, sugbọn awọn ọkunrin kan wa nibi bayi, ti wọn wà pẹlu mi nigbati gbogbo yin gbọ ti mo waasu iwaasu yẹn, “Ẹyin Alagba, Akoko Wo Ni?” Lowurọ ọjọ yẹn gan-an, nibiti O sọ pe yo wa, awọn angẹli meje duro sibẹ lati ọrun wá. Bi wọn si se n pada lọ sókè, ti ìjì afẹfẹ yẹn si gbe wọn lọ soke, awa duro, a n wo bi wọn se n lọ, imọ ijinlẹ ya aworan rẹ kaakiri orilẹ-ede, titi de Mexico.

91 Ati nibẹ nigbati mo n wo….

Lọjọ kan nigbati mo bẹrẹ si waasu awọn igba ijọ meje wọnyi, ti mo si pe Jack Moore, onimọ nla kan nipa ẹ̀kọ́ ẹ̀sìn; mo ni, “Jack, tani ẹni ti o duro sibẹyẹn, 'Ẹnikan wa bii Ọmọ Eniyan ti O duro sibẹ, irun Rẹ̀ funfun bii ẹ̀gbọ̀n òwú.'” Mo ni, “Ọdọmọkunrin ni; bawo ni o se le ni irun ti o funfun bii ẹ̀gbọ̀n òwú?”

O ni, “Arakunrin Branham, ara ologo Rẹ niyẹn.” Iyẹn ko tọ́ loju mi. Sugbọn nigbati mo wọ yara lọ, ti mo bẹrẹ si gbadura, Ó jẹ ki n mọ ohun ti o jẹ.

Se ẹ rii, mo ti maa nwaasu wipe Ó jẹ Ọlọrun, kii kan se eniyan lasan; O jẹ Ọlọrun ti o farahan ninu ẹran ara, Ọlọrun, èrò Ọlọrun ifẹ, awọn èrò nla ti Ọlọrun ti o sọkalẹ wa sori ilẹ aye ti o si farahan. Jesu ni ifẹ Ọlọrun, eyiti o da ara ti Jehofa funra Rẹ gbe inu rẹ. Oun ni ẹkunrẹrẹ Ọlọrun ninu ara. Ohun ti Ọlọrun jẹ, O fihan ninu ara yẹn. Ara yẹn nilati kú ki o baa le wẹ iyawo pẹlu ẹjẹ Rẹ.

92 E si kiyesii, kii se wipe a wẹ iyawo nikan, tabi dariji i nikan, sugbọn a daa lare. Se ẹ rii? Njẹ ẹ ti wo ọrọ “da lare” yii lati wo ohun ti o tumọ si? Fun apẹẹrẹ bayi, ti Arakunrin Green ba gbọ wipe mo ti n mu ọti, mo ti n se awọn nkan ti o buru, ki o si wa rii wipe n ko se e, ki o si wa sọ wipe, “Arakunrin Branham, mo dari ji ọ.”

O dari ji mi kẹ? N ko se e rara. Kini o n dari ji mi fun?“ Se ẹ rii? Sugbọn ti mo ba jẹbi, nigbanaa a le dari ji mi, sugbọn a ko tii da mi lare, nitori mo se e. Sugbọn ọrọ ”da lare“ ni wipe ”o kò tilẹ se e rara“ - da lare. Nigbanaa ẹjẹ Jesu Kristi wẹ wa mọ kuro ninu ẹsẹ, o si fi sinu iwe igbagbe Ọlọrun. Oun nikan ni o lee se e. Awa lee dari ji, sugbọn a ko lee gbagbe.

Mo le dari ji ọ, sugbọn gbogbo igba ni n o maa ranti wipe o se awọn nkan buburu wọnyi. Nigbanaa, a ko da ọ lare, a kan dari ji ọ ni. Sugbọn niwaju Ọlọrun, a da iyawo lare. Kò tilẹ fi igba kankan se e rara. Amin. O duro sibẹ, a fẹ ẹ fun Ọmọ Ọlọrun, ko fi igba kankan dẹsẹ. Kini idi? A ti yan-an tẹlẹ; a kan faa sinu nkan yii ni. Bayi ti o si ti gbọ otitọ, ti o si jade wa, ẹjẹ naa wẹ ẹ mọ. O si duro sibẹ lailabawọn. Se ẹ rii? Ko si ẹsẹ kankan ninu rẹ rara.

93 Nitorinaa, isẹ-ohun-Ọlọrun naa pe iyawo jọ papọ. Se ẹ rii? Ariwo ati ipe. Ẹni kanna pẹlu ariwo nla, O pariwo sita pẹlu ohun-ariwo yẹn, O si ji Lasaru. O kigbe pẹlu ariwo nla, “Lasaru, jade wa.” Se ẹ rii? Ohun naa yoo si ji iyawo ti o sun, awọn òkú ti o sùn.

Ati ipe naa, pẹlu didun ipe, nigbati o ba si se bẹẹ, yoo pè…. Ìpè maa n fi igbagbogbo pe Israẹli si àsè ti ìpè (se ẹ rii?), eyiti i se ase Pẹntikọsti, ase nla naa ni oju ọrun, ati ase ti awọn ìpè…. Ni bayi, ìpè wa fun ipejọpọ, ìpè si ase. Bayi, iyẹn jẹ ase ti Ọdọ Aguntan ni oju ọrun (ẹ kiyesii bayi,) - ipejopọ ninu iyawo, àsè ti ìpè, àsè igbeyawo.

A ti rii ninu apẹẹrẹ. Bayi, ẹ kiyesii fun iseju kan ki a to danu duro.

Ẹ kiyesii, a ti rii ninu apẹẹrẹ.

94 Bayi, ti ẹ ba fẹ ka a ni Matteu 18:16, o ni, awọn mẹta lo njẹri. Se ẹ rii? Ni I Johannu 5:7 ati bẹẹ bẹẹ lọ…. Mẹta maa n jẹ ẹri nigbagbogbo. Se bẹẹ ni? O jẹ ifidimulẹ, ohun ti o tọ. Awọn ẹlẹri mẹta lo njẹri…. "Ni ẹnu ẹlẹri meji tabi mẹta, ni ki a fi idi gbogbo ọrọ mulẹ."

Ẹ kiyesii bayi, a ti ni ẹlẹri mẹta. Mẹta jẹ ẹlẹri. Bayi, a ti ni igbasoke mẹta ni Majẹmu Laelae (njẹ ẹ mọ iyẹn?) gẹgẹbi ẹlẹri. Bayi, ẹ kiyesii. Enoku jẹ ọkan; Elijah naa jẹ omiran; Jesu naa jẹ omiran. Jesu ti o jẹ okuta pataki, O jẹri. Oun ni okuta pataki laarin Majẹmu Laelae ati Titun, nitori O nilati kọ́kọ́ kú, lẹyinnaa a gba A lọ soke. O kú, O wa saye, O si rin laarin wa, lẹyinnaa a gba A lo soke; nitori Oun ni okuta pataki ti o so mejeeji papọ. Lẹyin ajinde ati igbasoke Rẹ (ẹ wo o!), lẹyin ti O ti se iyẹn ti o si fihan wipe Majẹmu Laelae yẹn…. Gbogbo wa la mọ wipe a si Enoku nipo pada. A mọ wipe a mu Elijah lọ soke nipa iji (se bẹẹ ni?) ninu kẹkẹ ina. Jesu naa si kú, a sin I, O jinde, O si wà lori ilẹ aye, lẹyinnaa a gba A lọ soke, okuta pataki naa. Awọn mẹta niyẹn lati jẹri. Se bẹẹ ni?

95 Bayi, igbasoke kan ti kọja na. Se ẹ mọ iyẹn. Ẹ jẹ ki a wo o boya a le ka a ni kiakia. Ẹ jẹ ki a si Matteu ori 27, ẹ jẹ ki a si wo ẹsẹ 45 ti Matteu ori 27. Ẹ jẹ ki a wo o boya a le tete ri iyẹn bayi ki a si wo o boya a le ri diẹ mu jade lati inu eleyi, ti yoo ran wa lọwọ - 27 ati 45 ni mo ti kọ silẹ nibi. Ẹ jẹ ki a ka a.

Bayi lati wakati kẹfa, okunkun bo gbogbo ilẹ titi di ikẹsan….

Ni akoko wakati kẹsan Jesu kigbe lohun rara, wipe, Eli, Eli, lama, sabaktani? eyiti o tumọ si, Ọlọrun Mi…. eese ti lwọ fi kọ Mi silẹ?

Awọn kan ti o duro nitosi… gbọ ọ, wọn si wipe, Ọkunrin yii n pe … Elijah.

Kiakia ọkan ninu wọn sare, o mu kan-n-kan, o fi sinu ọti kikan, o fi sori ọpa kan, o si fi fun-Un lati mu.

Awọn ti o kù sọ wipe … ẹ jẹ ki a wo o boya Elijah yoo wa gba A la.

Jesu, lẹyin ti o ti kigbe … pẹlu ohun rara, jọwọ [Ohun nla kan, ohun nla, kiyesii, nigbati Jesu n ku lọ, Ó kigbe lohun rara.] jọwọ ẹmi Rẹ lọwọ.

Si kiyesii, asọ ikele tẹmpili faya si meji lati oke de isalẹ; ilẹ si mi titi, awọn okuta si fọ;

Awọn iboji si si, ọpọlọpọ ara awọn … ẹni mimọ ti o ti sun, jinde,

Wọn si jade kuro ni iboji lẹyin ajinde Rẹ, wọn si wọ inu ilu mimọ nni lọ, wọn si farahan ọpọlọpọ.

96 Igbasoke kan ti kọja na. Mẹta ti sẹlẹ ni Majẹmu Laelae fun awọn ti a ti pese silẹ, awọn ti Ọrọ Ọlọrun tọ wa. Se ẹ rii? Ọrọ Oluwa tọ Enoku wa. Ọrọ Oluwa tọ Elijah wa. Oun jẹ wolii. Se ẹ rii? Ọrọ Oluwa ni Jesu. Se ẹ rii?

Ẹ kiyesii ni Majẹmu Laelae, awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae wọnyẹn, nigbati igbasoke yii kọkọ sẹlẹ. Ẹ kiyesi ẹsẹ 50: Ohùn rara Rẹ ji awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae dide, ani gẹgẹbi ohun rara Rẹ se ji Jesu dide - tabi ji Lasaru dide. Se ẹ rii? Ohun rara naa ji i dide. A si mu ekeji sẹ ni II Tẹssalonika 4. Ẹ jẹ ki a ka a …. A sẹsẹ ka a laipẹ yii ni. Se ẹ rii? "Emi ko fẹ ki ẹ se alaimọ, ara, ni ti awọn ti o sùn, ki ẹ mase banujẹ, ani…." Iyẹn ni I Tẹssalonika 4:12-18. Iyẹn yoo jẹ igbasoke keji. Igbasoke keji yoo jẹ gbigba iyawo lọ soke.

97 Awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae ti lọ si iwaju Rẹ, a ti mu paradise kuro. Awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae goke lọ nipa ohùn rara Rẹ nigbati O kigbe, ti o si jọwọ ẹmi Rẹ lọwọ. Nitori kini? Ẹbọ naa, irubọ fun ẹ̀sẹ̀ wọn ti wọn ti n duro de …. Wọn gbagbọ wipe Ọdọ Aguntan ti o pe yẹn n bọ wa, wọn ti n se irubọ ọdọ aguntan. Nigbati O si kú, ti O jọwọ ẹmi Rẹ lọwọ, O kigbe lohun rara, awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae si jinde. Ẹ kiyesi ariwo ati ohun naa nibi yi, nkan kanna ni nigbati O ba n bọ. Se ẹ rii? O jọwọ ẹmi Rẹ lọwọ, nigbati O si se bẹẹ, ẹbọ naa pe, a si tu paradise jade; awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae si tun wa sori ilẹ aye lẹẹkan sii, wọn rin kaakiri ori ilẹ aye, wọn si wọle pẹlu Rẹ ninu igbasoke Rẹ.

98 Dafidi sọ nibẹyẹn pe, "Ẹ gbe ori soke, ẹyin ilẹkun ayeraye, ki a si gbe yin soke."

O de igbekun ni igbekun, O si fi ẹbun fun awọn eniyan. Nigbati awọn eniyan mimọ Majẹmu Laelae wọle pẹlu Rẹ, wọn ni, "Ta ni Ọba ododo yii?"

"Oluwa ogo, alagbara ninu ẹgbẹ ogun … ẹgbẹ ogun nla." Wọn wọle wa, wọn n yan. Jesu de igbekun ni igbekun. Oun si wá pẹlu awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae, wọn si wọ inu ilẹkun titun wọnyẹn loke, wọn wipe, "Ẹ gbe ori soke, ẹyin ilẹkun ayeraye, ki a si gbe e yin soke, ki ẹ si jẹ ki Ọba ogo ki o wọle."

Ohun naa dahun lati inu lọhun, wipe, "Tani Ọba ogo?"

"Oluwa ti o lagbara ni ogun." Awọn ilẹkun naa si gbaragada. Jesu Asẹgun si de igbekun ni igbekun fun

awọn ti wọn ti gbagbọ ninu Rẹ, Ọrọ naa si ti tọ wọn wa. Nibẹ awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae n duro sibẹ. O de igbekun ni igbekun, O goke lọ si ọrun, O ko awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae dani, wọn si wọle. Igbasoke kan ti kọja na.

Igbasoke ti o n kan ni II Tessalonika fun ijọ, iyawo, ki a ji i dide, ki a si gba a soke lọ sinu ogo. “Awa ti a wà laaye ti a si sẹ́kù (iyẹn ni ara ti o kù sori ilẹ aye) ki yoo saaju tabi di awọn ti o sun lọwọ; nitori ìpè Ọlọrun yoo kọkọ dun, awọn oku ninu Kristi yoo si jinde. (Se ẹ rii?) Awa ti o si wà laaye, ti a si sẹ́kù ni a o gba lọ soke pẹlu wọn.”

99 Ni ijelo, mo duro ni ẹgbẹ titi kan. Mo duro ni ẹgbẹ titi mo si n wo ayẹyẹ Yiyan Bi Ologun. Nigbati wọn si kọja lọ, ti wọn n lọ loju titi, mo duro sibẹ pẹlu ọmọdekunrin mi Joseph. Wọn wa … àkọ́kọ́ ni awọn ọkọ̀ ija ogun àkọ́kọ́, awọn ọkọ̀ ogun. Lẹyin iyẹn ni awọn ọkọ̀ ogun Sherman nla ti ogun titun, ati awọn ibọn nla-nla pẹlu ẹnu ibọn wọn ati … ohun ti wọn fi di ẹnu ibọn naa ati bẹẹ bẹẹ lọ. Lẹyin iyẹn ni awọn ọmọ ogun wá, awọn ìyá ti wọn ni irawọ wura. Lẹyin naa ni ọkọ̀ ayẹyẹ wá pẹlu … sọkalẹ wa…. Ọkọ ayẹyẹ naa sọkalẹ wá, ati niwaju rẹ ni ibojì kan fun ọmọ ogun ti a kò mọ; ọmọ ogun kan si duro sibẹ, ti o jẹ ẹ̀sọ́ nibi iboji naa. Ọmọ ogun oju omi kan duro si ẹgbẹ kan, ati atukọ̀ oju omi kan ni ẹgbẹ keji. Wọn si pa aala kan sibẹ, ati ni odikeji ni iya kan wà, pẹlu irawọ wura. Ọmọkunrin rẹ ti ku. Ọdọbinrin iyawo kan wa nibẹ, ti o gbe ori rẹ le tabili, ti o si n sọkun, ati ọmọ alakisa kan ti o joko si ẹgbẹ kan, omije n bọ loju tirẹ naa, baba rẹ ti ku. Mo ronu, “Iru ibanujẹ wo ni eyi, bi mo se duro sihin yii ti mo n wo, mo ri awọn ogbó … awọn ọmọ ogun diẹ ti o kù, wọn n yan lọ, awọn arọ ati arugbo, bẹyẹn, pẹlu asọ ogun wọn, sugbọn wọn fi I han pẹlu iyangan, nitori wọn jẹ ọmọ Amẹrika.”

Mo ronu pe, “Ah, Ọlọrun mi,

100 lọjọ kan ariwo nla kan yoo ti ọrun wa, awọn oku ninu Kristi ni yoo si kọ jinde. Awọn ẹni mimọ Majẹmu Laelae ti o wa nibẹyẹn, ti wọn n duro, yoo kọkọ jade wa lati ibẹyẹn, wọn yoo wọ inu ajinde lọ; awa naa yoo si tẹle wọn lọ si ofuurufu, ara kiku yii yoo yipada, yoo si dabi ara ologo Tirẹ. Iru ayẹyẹ wo ni iyẹn yoo jẹ nigbati a ba n lọ si ọrun lọjọ kan, ni àkókò igbasoke ti o wa niwaju wa, ah, ti a o maa fi ẹjẹ Jesu Kristi yangan ni aya wa, isẹ-ohun-Ọlọrun ni wakati ti wọn gbe. Akoko ti a n foju sọna fun niyẹn, arakunrin.

Ẹ woo (ni ipari bayi), ajinde keji, ti àkọ́kọ́ ti koja. Ekeji ti sunmọ tosi bayi, yoo de - o sunmọ tosi bayi.

Bayi, ẹkẹta ni awọn ẹlẹri meji ti Ifihan 11:11 ati 12, awọn wọnyi ni o pada wa pẹlu Ẹmi Kristi lati jẹri fun awọn Juu bi Josefu se se si awọn arakunrin rẹ. Ẹ si ranti wipe òkú wọn wà ni igboro fun ọjọ mẹta ati aabọ; lẹyinnaa ẹmi ìyè wọ inu wọn, a si gbà wọn lọ soke, a mu wọn lọ soke ọrun. Igbasoke mẹta ti Majẹmu Titun yin niyẹn. Igbasoke mẹta ti Majẹmu Laelae, gbogbo wọn ti kọja.

Bayi, ati setan, a nduro de igbasoke awọn ẹni mimọ. A ti sọ ọ, bẹẹ ni yoo si ri.

Nigbati Ọlọrun ba sọ ohunkohun, ọrun oun aye yoo kọja lọ, sugbọn Ọrọ yẹn ko lee kuna laelae.

101 Nigbati Ọlọrun sọ nibẹyẹn ni Gẹnẹsis 1, O ni, “Jẹ ki imọlẹ ki o wa.” O ti le jẹ ọgọọgọrun ọdun ki imọlẹ kankan to wà. O ni, “Ki igi ọpẹ ki o wa; ki igi osè ki o wa; jẹ ki asalẹ ki o wà; jẹ ki òkè ki o wà; jẹ ki eleyi ki o wà.” Ó sọ ọ́. Se ẹ rii? Niwọn igba ti o ba ti ti ẹnu Rẹ jade gẹgẹbi ọrọ, o nilati farahan. O nilati ri bẹẹ.

Lọjọ kan, O pe awọn eniyan Rẹ jade, O si ba okunrin kan sọrọ ti a n pe ni Mose lati inu ọ̀wọ̀n ina, imọlẹ kan, imọlẹ ina mímọ́. Mose ko si fẹ…. Awọn eniyan naa ko fẹ gba Mose gbọ, nitorinaa O sọ pe, “Mu wọn jade wa sori oke yii.”

Lowurọ ọjọ yẹn, oke naa kun fun ina, ati manamana, ati ààrá, bẹyẹn, awọn eniyan naa si sọ pe, “Mase jẹ ki Ọlọrun sọrọ; jẹ ki Mose sọrọ (se ẹ rii?), ki a ma baa segbe.”

Ọlọrun sọ pe, “N ko ni ba wọn sọrọ bi eleyi mọ, sugbọn n o gbe wolii kan dide fun wọn. N o si sọrọ nipasẹ rẹ, ti ohun ti o ba sọ ba si sẹ, nigbanaa, ẹ gbọ tirẹ, nitori Mo wà pẹlu rẹ.” Bayi, O so iyẹn. O sọ wipe yoo wa si imusẹ.

102 Ẹ wo wolii Isaiah ti o duro sibẹyẹn, ọkunrin kan, olóye eniyan, ẹniti ọba ka si pataki, nitori o ti ba ọba Ussiah gbe, ti o jẹ ẹni nla. O gbiyanju lati gba ipo oniwaasu nigbakan, o si wọle lọ, a si da ẹtẹ lu u. Ohun ti mo sọ fun Ẹgbẹ Awọn Onisowo niyẹn. Laelae, ẹ mase gbiyanju lati gba ipo oniwaasu. Rara, sa! Ẹ duro sibi ti ẹ wa. Se ẹ rii? Ẹyin ẹ se isẹ yin, ohun ti Ọlọrun sọ fun yin. Ti o ba jẹ ìka, o ko lee jẹ etí. Ti o ba jẹ etí, o ko lee jẹ imú, imú ko lee jẹ ojú. Se ẹ rii? Ẹ duro ni aaye yin.

Ẹ gbọ iwaasu yẹn ni ijelo lori redio. “Gbigbiyanju Lati Se Isẹ-Isin Fun Ọlọrun.” Dafidi, ọba ti a fi ami-ororo yan, gbogbo awọn eniyan n pariwo, wọn n kigbe wipe o dara, sugbọn ko beere lọwọ wolii Ọlọrun. Ọkunrin kan si kú, gbogbo rẹ si baje. Mase gbiyanju lati se ojurere si Ọlọrun. Iwọ duro de akoko Ọlọrun. Jẹ ki o wá ni

ọna ti Oun fẹ gba se e. “Emi yoo bẹrẹ nkan yii, yoo se bayi.” Arakunrin, sọra.

103 Bayi, Dafidi mọ ju iyẹn lọ, Natani wa ni ilu lọjọ yẹn. Ko tilẹ beere lọwọ rẹ rara. Se ẹ rii? Ó ba awọn balogun ọgọrun ati ẹgbẹrun sọrọ. Gbogbo awọn eniyan kigbe, wọn pariwo, wọn jo, ati [awọn ọrọ ti a kò gbọ daradara]. Wọn ni gbogbo isẹ-ijọsin, sugbọn kò ba ilana ati Ọrọ Ọlọrun mu, o si kuna. Ohunkohun miiran ti kò ba ilana ati Ọrọ Ọlọrun mu, yoo kuna. Ọrọ Ọlọrun nikan ni yoo duro titi laelae. “Ọrun oun aye yoo kọja lọ, ayafi Ọrọ Mi nikan.”

104 Ẹ kiyesi Isaiah, ọlọgbọn ọdọmọkunrin ti o duro sibẹyẹn. Lojiji, Ẹmi ba le e. Ko le sọ nkan miiran, wolii ni. O ni, “Kiyesii, wundia kan yoo loyun. A bi ọmọkunrin kan fun wa … a bi ọmọ kan, a fi ọmọkunrin kan fun wa. A o pe orukọ Rẹ ni Oludamọran, Ọmọ Alade Alaafia, Ọlọrun Alagbara, Baba Ayeraye. Opin Tirẹ…. Ijọba yoo wà ni ejika Rẹ, ijọba Rẹ ki yoo si lopin.” Bawo ni ọkunrin ọlọgbọn yẹn se le sọ wipe wundia yoo loyun? Gbogbo eniyan ni o foju sọna fun-un. A ti sọ ọ na; “Bayi ni Oluwa wi ni.” Ó gbọdọ wa si imusẹ, nitori Ọrọ Ọlọrun ni, bi o se ri ni Gẹnẹsisi nigbati O gbin awọn irugbin yẹn si isalẹ òkun, nibiti o wà ni juu-juu ti o si sofo, ti omi si bo ibú mọlẹ. Se ẹ rii, ó nilati wá si imusẹ.

Bẹẹni lọjọ kan, lẹyin ẹgbẹrin ọdun, ile-ọmọ wundia kan loyun iru Ọlọrun, iru ti a da. O bi Ọmọkunrin kan. Ọmọkunrin yẹn si duro nibẹ lọjọ kan, O si wipe, “Lasaru, jade wa.” Ọkunrin ti o si ti kú fun ọjọ mẹrin, ti o ti ra, imú rẹ ti jìn sinu, o ti n rùn; o jade wa. O ni, “Ẹ mase jẹ ki eleyi ya yin lẹnu, nitori akoko n bọ (amin) nigbati gbogbo awọn ti o wà ninu ibojì yoo gbọ ohun Ọmọ Ọlọrun.” Nitorinnaa, a ti sọ ọ; ó gbọdọ wa si imusẹ. Igbasoke yoo wa.

Akiika!

105 Mo ranti iwaasu mi ti o kẹyin ni Kalifọnia, nibi ti mo ro wipe n ko ni pada si mọ laelae, nigbati mo sọtẹlẹ wipe Los Angeles yoo jin sinu okun. “Bayi ni Oluwa wi,” yoo ri bẹẹ! O ti tan fun-un, a ti gbá a lọ, o ti tan fun-un. Igba wo? Emi ko mọ igba, sugbọn yoo jin. Kete lẹyin iyẹn, awọn ilẹ bẹrẹ si gbọn riri.

Ẹ ranti, ọpọ ẹyin ọkunrin ni ẹ wà nibi okuta yẹn ni ọjọ yẹn, nigbati angẹli naa sọkalẹ sibẹ, ti imọlẹ ati ina si nsọkalẹ lati ọrun, ni ayika apata ibi ti wọn duro si, awọn okuta n fọ́n jade lati oke naa, wọn si n bọ́ si ibẹ. O si dun gidigidi ni igba mẹta; mo ni, “Idajọ yoo la Ìpẹ̀kun Ìwọ̀ Oorun kọja.” Ọjọ meji lẹyin iyẹn, Alaska fẹrẹ jìn wọlẹ.

106 Ẹ ranti, Ọlọrun kanna ti Ó sọ iyẹn, Oun naa lo sọ wipe Los Angeles ti sègbé. O ti tan. Emi ko mọ igba; n ko lee sọ fun yin.

N ko mọ wipe mo sọ bẹẹ. Sugbọn mo gbagbọ wipe arakunrin yii nibi… Rara, mo gbagbọ wipe ọkan ninu awọn Moseley, pe mi lọ si ita nibẹyẹn. N ko si mọ ohun ti o jẹ ayafi igba ti mo to pada yẹẹ wo. Mo si lọ yẹẹ wo ninu Iwe Mimọ, Jesu wipe, “Kapanaumu, Kapanaumu, yoo ti pẹ to…. Iwọ ti o gbe ara rẹ ga (tabi) lọ si oke ọrun, a o fa ọ walẹ sinu ọrun apaadi, nitori ti a ba ti se isẹ ti a se ninu rẹ ni Sodomu, iba sì wà titi di oni yii.” Ni nkan bii aadọjọ ọdun si igba yẹn - Sodomu ti wa ninu ilẹ - Kapanaumu si n bẹ ninu omi loni.

107 Ẹmi Ọlọrun kannaa ti O sọ awọn nkan wọnyi, ti O si se awọn nkan wọnyi, o sọ nibẹ pe, “Ah, iwọ ilu, Kapanaumu, iwọ ti o n fi orukọ awọn angẹli pe ara rẹ, Los Angeles. Iwọ ti gbe ara rẹ ga de ọrun to (Gbongbo ati ibujoko Satani gan-an. Se ẹ rii?). Ó ti gbé ara rẹ̀ ga.”

Iboji oku ni ibẹ fun awọn oniwaasu. Awọn eniyan rere a lọ sibẹ, wọn a si ku bii èkúté. Iru ibajẹ wo niyẹn.

“Iwọ ti o n fi orukọ awọn angẹli pe ara rẹ, ibasepe awọn isẹ agbara ti a se ninu rẹ, a se wọn ni Sodomu ni, iba si wa titi di oni yi. Sugbọn àkókò rẹ ti de.” Ẹ kiyesii ki ẹ si wò ó. Ti kò bá rí bẹẹ̀, a jẹ wipe wolii èké ni mi. Se ẹ rii? O wà nibẹ, o duro sibẹ.

108 Mo ranti alẹ ọjọ yẹn… Ki n to ri iyẹn, mo ri aworan iyawo. Mo duro sibẹ mo si ri ọdọmọbinrin kan ti o rẹwà, ó mura daradara ati bẹẹ, o n yan lọ ni ọna yii. Ẹnikan duro ti mi ninu iran naa, ẹni yẹn si wipe, “Aworan ti iyawo naa.” Mo ri i ti o kọja lọ. Wọn gba ẹgbẹ ibi yii wa, wọn si yipo.

Mo si gbọ ti o n goke bọ; ijọ n ti apa ibi yii bọ. Ijọ Asia wa. Ah, ti a ba nsọrọ nipa ẹgbin. Ijọ ti Europe naa wa. Kai!. Lẹyinnaa, mo gbọ orin taka-nsufe ti o n bọ; o si jẹ Ọmọbinrin Amẹrika, ijọ. Ko tilẹ wọ asọ kankan. O kàn ni ìwé, bii iwe-iroyin, alawọ eérú, o fi si iwaju rẹ, o njo ijo taka-nsufe - Ọmọbinrin Amẹrika, ijọ.

Mo duro sibẹ niwaju Rẹ̀. Mo ronu pe, “Ah, Ọlọrun, gẹgẹbi iransẹ Ọlọrun, ti o ba jẹ wipe ohun ti o dara ju ti a lee se niyẹn, ah, ah!” Ẹ mo bi o se ri lara. Mo wa ronu pe, “Ọlọrun, fi mi pamọ, ti mo ba saa lee kuro nibi yii. Ti o ba jẹ wipe pẹlu gbogbo ohun ti a ti se, ohun ti a ri mu jade niyẹn, ti o ba jẹ iyẹn ni….”

109 Nigbati awọn obinrin yẹn si kọja lọ tan, ti gbogbo wọn n se orisirisi awọn nkan, pẹlu irun kukuru, ati oju ti wọn kun ni ọ̀dà. Bi wọn si se kọja lọ bẹyẹn, ti o si yẹ ki wọn jẹ wundia fun Kristi. Nigbati o si kọja lọ bẹyẹn….

mo yi ori pada, ẹ mọ, pẹlu … wọn kàn mu iyẹn siwaju wọn, ohun itiju ni, ẹyin wọn. Wọn si n lọ bẹyẹn.

Mo si yi oju pada, mo n sọkun. Mo ni…. N ko lee farada a, ti Oun sì duro sibẹ, ti mo si mọ wipe emi jẹ iransẹ Ọlọrun fun ijọ, wipe ohun ti mo ri mu jade fun-Un niyẹn. Mo ni, “Ah, Ọlọrun, n ko lee wo o. Jẹ ki n kú. Jẹ ki n poora,” ati bẹyẹn.

Ni kété ti wọn kọja lọ - gbogbo igba ti ọ̀kan ninu wọn ba wá, wọn yoo kọja lọ si ibi kan, wọn yoo sì subu kuro, n o si gbọ ohun rẹ̀ bi o se kọja lọ. Lẹyinnaa mo gbọ kini kan bii “Ẹ Maa Tẹsiwaju.” Mo si wo, mo ri awọn ọdọmọbinrin mimọ yẹn ti wọn n pada bọ, wọn ri bi wọn se ri ni àkọ́kọ́, gbogbo wọn mura daradara, irun wọn gùn de ẹyin wọn, wọn jọ̀lọ̀, wọn mọ́, wọn n yan bayi si ìgbésẹ̀ ihinrere. Oun ni Ọrọ naa. O dabi ẹnikọọkan lati orilẹ-ede kọọkan. Mo n wo o bi wọn se n kọja lọ, mo si ri wọn ti wọn kọja lọ. Dipo ki wọn maa lọ si isalẹ, òkè ni wọn n lọ. Mo si kiyesi ọ̀kan ninu wọn ngbiyanju, awọn meji tabi mẹta ninu wọn ngbiyanju, wọn fẹ kuro lori ila. Mo pariwo, “Ẹ duro lori ila!” Iran naa si fi mi silẹ, mo si duro sinu yara yii, mo n pariwo, “Ẹ duro lori ila!” Ila ti….

110 O yà mi lẹnu, ó ha ti le kọja bi? A ha ti le pe iyawo bi? Se ohun ti a n la kọja loni niyẹn bi? A nilati mọ̀ ọ́, ki a si sọ ọ di aworan Kristi, Kristi si ni Ọrọ naa. Ohun kansoso niyẹn. Se ẹ rii, o wa nibẹ, ninu Ọrọ, o kan…. Ẹ rii, a ko lee fi ohun kan kun-un. Ko lee jẹ obinrin ti o ni ọwọ́ kan bii ti eniyan, ki ọwọ́ keji si dabii ti aja; o nilati jẹ Ọrọ Ọlọrun gẹẹ, bi Oun naa se jẹ Ọrọ. Iyawo jẹ ara ọkọ iyawo. Obinrin jẹ apakan ara ọkọ rẹ, nitori a mu u lati ara ọkọ rẹ. Eefa jẹ apakan ara Adamu lati ẹ̀gbẹ́ rẹ̀. Bẹẹ naa ni iyawo, a kò mu u lati inu ijọ ẹlẹkọ adamọ, sugbọn a mu u lati oókan aya Ọrọ Ọlọrun fun ọjọ oni.

111 Igbasoke;

Ipe Oluwa yoo dun;

Awọn oku ninu Kristi yoo jinde,

A o si pin ninu ogo ajinde Rẹ;

Nigbati awọn ayanfe ba pejọ pọ

si ile wọn loke,

gbat'aba n porukọ lọhun….

(Ẹ jẹ ki gbogbo wa gbiyanju lati wa nibẹ, ẹyin ọrẹ.)

Ki Ọlọrun bukun yin. A ti sọ ọ; o nilati sẹ. Yoo wa si imusẹ! Awọn ẹgbẹ eniyan kekere, kò sí ẹni ti o fẹ kú; ko si ẹni ti o fẹ sọnu. Ẹ jẹ ki n sọ fun yin, ohunkohun ti ẹ ba n se, n ko bikita bi ẹ se lọ si ile-ijọsin to ati bi ẹ se jẹ olootọ si ile-ijọsin to… Iyẹn dara; ko si ohun ti o lodi si iyẹn; ẹ gbọdọ maa lọ si ile-ijọsin. Ẹ maa se bẹẹ; ẹ maa lọ si ile-ijọsin, sugbọn ohun yoowu ti o jẹ, ẹ sọ àsà yin si igbo, ki ẹ si tẹsiwaju lati wọ inu Kristi; nitori ìpè yoo dun ni ọjọ kan, a o si ba ọ pẹlu ami ẹranko naa lara rẹ, o kò si nii mọ ohun ti o jẹ́, titi ti yoo fi pẹ ju. Bẹẹ gan-an lo ri!

112 Ki Ọlọrun bukun yin. Mo tọrọ aforiji wipe mo da yin duro. Ẹ si ranti, mo ti da wọn duro pẹ pupọ nihin; bẹẹ ni. Ọrẹ ti ẹ si gba fun mi, ti n ko si sọ wipe ki ẹ se bẹẹ, Arakunrin… Temi ni …. Iwa ọmọluabi niyẹn. Ẹ mu owó yẹn, ki ẹ fi san owo ile-itura yii fun lilo kọja akoko, nitori mo fi pamọ. Mo kan ni awọn nkan diẹ nihin. Mo si ni oju ewe bii mẹjo si mẹwa lori igbasoke yẹn, sugbọn n ko ni akoko to lati fun yin.

Ki Ọlọrun bukun yin! Se ẹ fẹran Jesu Oluwa? Ẹ jẹ ki a dide duro jẹẹjẹ bayi, fun bi isẹju kan, ni idakẹjẹẹ, tọwọtọwọ. Ẹ si ranti ohun ti mo ti sọ. Ẹ ranti, a ti wa ni wakati ti o gbẹyin. Awọn….

Awọn orilẹ-ede n wo palẹ;

Israẹli n ji dide;

Awọn ami ti Bibeli ti sọtẹlẹ;

Ọjọ awọn Keferi ku si dẹdẹ

Pẹlu ọpọlọpọ ohun ẹ̀rù.

Pada, ẹyin asako, si ile yin.

Ọjọ irapada ku si dẹdẹ;

Ọkan awọn eniyan n fò fun ẹ̀rù.

Kun fun Ẹmi,

Tun atupa rẹ se, ki o maa jo geregere,

Ẹ woke, irapada yin sunmọ tosi.

(Ẹ mọ iyẹn bi?)

Awọn wolii eke n puro;

Wọn n sẹ otitọ Ọlọrun; (A mọ

wipe otitọ ni gbogbo rẹ, tabi a ko mọ?)

……..

Mo fẹran Rẹ, Mo fẹran Rẹ,

Nitori Oun lọ kọ fẹ mi,

O si ra igbala mi

Lori igi Kalfari.

Ẹni melo lo fẹran Rẹ nitootọ, ẹ na ọwọ yin soke. Bayi, bi a se tun n kọ orin yii, mo fẹ ki ẹ bọwọ́ pẹlu ẹnikan ti o wa ni ẹgbẹ yin, ki ẹ si wipe, “Ki Ọlọrun bukun yin, arinrinajo!” Arinrinajo ni wa, abi bẹẹkọ, arinrinajo ati alejo?

Mo fẹran Rẹ (Bẹẹ ni, ni odikeji

tabili.) Mo fẹran Rẹ,

Nitori Oun lo kọ fẹ mi,

O si ra igbala mi

Lori igi Kalfari.

113 Se o fẹ lọ ninu igbasoke? Ẹni melo lo nifẹ lati lọ ninu igbasoke, sọ pe, “Ọlọrun, mo fe de ibẹ pẹlu gbogbo ọkan mi.”

“Di Ọwọ Ọlọrun Ti Kii Yipada Mu.” Se ẹ mọ orin yẹn? Arabinrin, se ẹ mọ̀ ọ́? “Di Ọwọ Ọlọrun Ti Kii Yipada Mu.” N ko mọ ohun… Inu ibiti o wa? Ki ni… Uh?

Di ọwọ Ọlọrun ti kii yipada mu!

Di ọwọ Ọlọrun ti kii yipada mu!

Fi ireti rẹ sinu awọn nkan ainipẹkun,

Di ọwọ Ọlọrun ti kii yipada mu!

Se ẹ fẹran iyẹn?

Nigbati irin ajo wa ba pari,

Ti o ba ti jẹ olootọ si Ọlọrun,

Ile rẹ didan ninu ogo,

Ọkàn ayọ̀ rẹ yoo rii!

Di ọwọ Ọlọrun ti kii yipada mu!

Di ọwọ Ọlọrun ti kii yipada mu!

Fi ireti rẹ sinu awọn nkan ainipẹkun,

Di ọwọ Ọlọrun ti kii yipada mu!

Mo fẹ ki ẹ tẹri yin ba fun igba diẹ bayi.

Mase se ojukokoro awọn ọrọ̀ asan aye yii,

Ti kii pẹ rà,

Wa ọna lati jere isura ọrun,

Wọn ki yoo kọja lo laelae!

Di ọwọ Ọlọrun ti kii yipada mu!

Di ọwọ Ọlọrun ti kii yipada mu!

Fi ireti rẹ sinu awọn nkan ainipẹkun,

Di ọwọ Ọlọrun ti kii yipada mu!

114 Bayi, pẹlu ori yin ni titẹba ati eleyi ninu ọkan, bi a ti mọ wipe a n tẹriba si erùpẹ̀ nibiti a ti mu wa jade, lọjọ kan a o si pada sibẹ; bi o se mọ wipe o ni ọkan kan nibẹyẹn ti o nilati jihin fun Ọlọrun…. Ti o bá si mọ̀ wipe o koi tii setan fun igbasoke yẹn, wipe ti o ba sẹlẹ ni alẹ oni, ti o si fẹ ki a ranti rẹ ninu adura, saa na ọwọ rẹ soke. A ko ni aaye lati pe awọn eniyan si ibi pẹpẹ. Ọkan rẹ ni pẹpẹ rẹ. Na ọwọ rẹ soke. Ki Ọlọrun bukun yin, ati ẹyin, ati ẹyin. Ah! “Mo lero wipe n koi tii mura silẹ, Arakunrin Branham. Mo tilẹ fẹẹ jẹ Kristẹni nitootọ. Mo ti gbiyanju lati jẹ bẹẹ, sugbọn kini kan wa ti o sọnu. Mo mọ wipe n ko si nibiti o yẹ ki n wà. Ọlọrun, saanu. Mo na ọwọ mi soke, saanu fun mi.” Bayi, ọwọ bii ogun tabi ọgbọn ni o ti wà loke laarin ẹgbẹ kekere yii. Ọpọ ọwọ ni o si tun n lọ soke.

115 Ọlọrun ọwọn, O mọ ohun ti o wà lẹyin ọwọ yẹn, ninu ọkan. Mo gbadura, Ọlọrun ọwọn…. Ohun kan ni mo ni ojuse fun, oun ni lati sọ otitọ. Ọlọrun ọwọn, wọn n fẹ ki a gbà wọn là. Wọn n fẹ nitootọ… Wọn kò fẹ ìjìlára lasan, ẹ̀gbọ̀nrìrì kan lasan, ijọ ẹlẹkọ-adamọ kan lasan, ẹkọ adamọ kan, ẹkọ eniyan kan ti a fi kun-un. Wọn mọ, Baba, wipe ó gba Ọrọ Ọlọrun ti o pé, laini abula. Ohun gbogbo ti o kù ni yoo kọja lọ, ani ọrun oun aye pẹlu, sugbọn Ọrọ naa kò nii kọja lọ. Ti awa ba si jẹ Ọrọ yẹn, aye yoo kọja lọ labẹ wa, sugbọn awa ko ni kọja lọ, nitori a jẹ Ọrọ yẹn, iyawo ti ọkọ-iyawo.

Mo gbadura fun olukuluku wọn, wipe ki O fi fun wọn, Baba, ni adura mi tọkantọkan… Baba, dariji mi, wipe ara mi ko balẹ ni alẹ yii, mo pẹ ki n to de, ara mi si n gbọn, mo si n sọ ọrọ ti a ge nihin, ge lọhun. Lọna kan abi omiran, Ẹmi Mimọ nla, so wọn papọ ni ọna atọrunwa Tirẹ. Ki o si fi sinu ọkan awọn eniyan lati ọkan mi wa, pẹlu ilepa ati erongba atọkan mi wa ti mo ni si Ọ. Iwọ ki yoo ha se e bi, Oluwa. Ki o si gba awọn ẹniti o se e gbala, fa wọn mọra, Oluwa. Jẹ ki a mura silẹ fun wakati igbasoke yẹn ti o sunmọ tosi. Nitori mo beere ni orukọ Jesu. Amin.

Ki Ọlọrun bukun yin. Bayi, alaga agọ ajọ.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu
William Marrion Branham
"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7